# JÍJA ÀWỌN OGUN AYÉ RẸ

Mary Owólabí

Ilé-iṣẹ́ aṣèwetà tó ṣe ìwé yìí ni:
**Straight-Gate Publishers Limited**
46, Water Bus-Stop, Opposite U.I, Oyo Road.
P. O. Box 22703, Ibadan.
Tel: 0803-324-7775, 0805-670-7522

Díákónì Obìnrin Mary Owólabí, 2017

**ISBN:** 978-978-52841-7-1

**Àṣẹ tí a Kò fún ni.**
Pé a kò fún ẹnikẹ́ni láṣẹ láti tún kọ tàbí dàkọ apá kan nínú ìwé yìí ní ọ̀nàkọnà yálà nípa ẹ̀rọ ayárabíàṣá tàbí àwọn ọ̀nà mìíràn láì gba àṣẹ láti ọwọ́ òǹkọ̀wé; àyàfi lílò fún bíi àkàjúwe tí ó ṣe kókó.

Gbogbo àkàjúwe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí a lò jẹ́ ti ìwé mímọ́ King James Version àti New Living ti Bíbélì Mímọ́.

Fún àdúrà àti ọ̀rọ̀ ìmọ̀ràn, jọ̀wọ́ pe òǹkọ̀wé sórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ yìí:
+2348140606077; 07055512708
**Ẹ̀rọ ayárabíàṣá:**
thedivinemessageandgreatmissio@gmail.com

# TÁBÌLÌ ÀKÒRÍ

Ìpè Iránṣẹ́ ... ... ... ... ... v

Ìfijì ... ... ... ... ... ... vi

Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ ... ... ... ... ... vii

Ìfáàrà ... ... ... ... ... xi

Ìmọrírì ... ... ... ... ... xii

Ọ̀rọ̀ Ìsáájú ... ... ... ... ... 1

**ORÍ KÍNNÍ**
Mímòye Ìjagun ti Ẹ̀mí ... ... ... 12

**ORÍ KEJÌ**
Ibi Gíga ... ... ... ... ... 21

**ORÍ KẸTA**
Alágbára Ọkùnrin ... ... ... ... 40

**ORÍ KẸRIN**
Ọgbọ́n àti ja Ìjà ti Ẹ̀mí ... ... ... 54



**ORÍ KARUN**
Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ti Ẹ̀mí ... ... ... 75

**ORÍ KẸFÀ**
Àwọn ọmọ ogun Ọlọ́run fún
Ogun Ẹ̀mí ... ... ... ... ... 88

**ORÍ KEJE**
Ní Ìparí, Iṣẹ́gun Dájú ... ... ... 96

# ÌPÈ ÌRÁNṢẸ́

Ẹni tí Ọlọ́run pè tí ó sì rán láti dín èrò ìjọba èṣù kù ní kíkọsílẹ̀ nípa ìtọ́ni àti ìfíhàn àtọ̀runwá àti títọ́sọ́nà nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́, láti tú àṣírí tí ó n darí ẹni sí ìsọdi ọ̀mìnira àti láti sìpẹ̀ fún àti láti gba àwọn ọmọ Ọlọ́run níyànjú ní gbogbo ayé, kí á ba le jèrè wọn padà sínú ìjọba Ọlọ́run tó ga jùlọ.



# ÌFIJÌ

Mo fi iṣẹ́ ìwé yìí jì fún Ọlọ́run alágbára tí ó nìkanṣoṣo jẹ́ orísun ìmísí mi, fún ore ọ̀fẹ́ àti àánú àtọ̀runwá Rẹ̀ lórí ayé mi, ìwọ nìkan ni ó yẹ láti yìn àti láti júbà, Bàbá mi.

# ỌRỌ ÀKỌSỌ

Ó jẹ́ dídùn inú mi láti pèsè àwọn èrò ìkínikúàbọ̀ sí ìwé yìí, èyí tí ó dé ní àkókò ewu ìgbẹ̀yìn ìrìn àjò Krìstẹ́nì wa yìí, tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ onígbàgbọ́ n kùnà tí wọ́n sì n jà bí ẹni tí n lu afẹ́fẹ́ tí ó bá dé ibi ìwọ̀yá ìjà ti ẹ̀mí.

Bíbélì so pàtó wípé ogun ni ìgbésí ayé wa jẹ́ àti pé ní àyíká àwọn ọ̀tá wa ni à n gbé (bíbélì pè é ní ọmọ ọba ayé yìí). Síbẹ̀ púpọ̀ jù nínú àwọn Krístẹ̀nì sọ ogun púpọ̀ nù jù èyí tí wọ́n borí lọ,wọ́n sì n fi ara da ìrìn wọn pẹ̀lú Ọlọ́run nígbàtí ó yẹ kí wọ́n máa gbádùn rẹ̀, nítorí pé wọn kò dá ọ̀tá mọ̀ nígbàtí wọ́n bá ri. Ní pàtàkì jùlọ, wọn kò ní òye bí wọn ó ti dáhùn, wọ́n ṣe àìní àwọn ọgbọ́n bí a ti ṣe í wọ̀yá ìjà ti ẹ̀mí.



Krìstẹ́nì gbọ́dọ̀ ní ọgbọ́n dídánilóhùn sí àwọn ọtá ti a ti fihàn gbangba wọ̀nyí, ní kíkọ́ láti jà pẹ̀lú bíbélì àti pẹ̀lú àbájáde tí ó péye ju pé kí á sa ma jà nítòótọ́ lọ. Ònkọ̀wé yìí, Díákóni obìnrin Olúwakẹ́mi Mary Owólábí, tí ó gba ìpè  Ọlọ́run sí iṣẹ́ pàtàkì yìí láti máa kọ ìwé tí ó dá lórí ìgbàgbọ́ krìstẹ́nì àti ìrìn ìṣẹ́gun pẹ̀lú Ọlọ́run nípa ìfihàn Ọlọ́run àti ìmísí àtọ̀runwá - ti kọ ìwé àtọ̀runwá yìí tí a pe àkọ́lé rẹ̀ ní "Jíja Àwọn Ogun Ayé Rẹ" fún àbò tí ó rọrùn, tí ó bá ìlànà bíbélì mu, tí kìí síí ṣe àtọwọ́dọ́wọ́.

Nípasẹ̀ ìfihàn ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nínú ìwé yìí, ó yé wa yéké wípé a ní ogun nlá láti jà àti láti bórí nínú wa ju ní ojúta wa lọ. A ní láti mọ̀ wípé ogun náà kìí ṣe tiwa, sùgbọ́n ti Ẹ̀mí Mímọ́ tí n gbé nínú wa. Ohun tí ó ṣòro í ṣe jù fún ọ̀pọ̀ onígbàgbọ́ ni pé kí á kúrò ní ọ̀nà tí ẹ̀mí n gbà. Nígbàtí a bá kùnà láti fi àkóso ara wa fún, àkóso lórí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àti ohun tó n ṣẹlẹ̀ ní ayé wa ní

lémọ̀lémọ̀. Ìwé náà tú àṣírí wípé ọ̀tá máa nbá wa jà nípasẹ̀ ẹ̀dá ìgbà àtijọ́ wa tí ó ti subú, àti nípa àwọn ìdẹwò tí ó yí wa ká kiri. Sùgbọ́n, à ní agbára láti yàn, a kì í ṣe aláìní ìrànlọ́wọ́ nínú ìjàgbara yìí.

Tí a bá fi àkóso ara wa fún ẹ̀mí, àwá yí ò kún fún ẹ̀mí, bí Olúwa ṣe n gbà tí Ó sì n mọ ayé wa sí àwòrán Krístì. Bí á bá ṣe n fi ara wa sílẹ̀ sí, ní à n dàbí Krístì sí, nípa bẹ́ẹ̀, à n borí ogun tí ó tóbi jù pẹ̀lú ara. Nígbàtí a bá sì ti borí ara wa, nígbà náà ni a ti borí àwọn ọ̀tá lóde - àwọn ìjòyè, ọlọ́lá, aláṣẹ ibi òkùnkùn, àjẹ́ àti oṣó, yíò di eré ọmọdé.

Ìwè yìí ti fi ọwọ́ tọ́ mi, ó sì ti bùkún mi lọpọ̀lọpọ̀ nítorí ó fi yé ni lọ́tun, ó sì fi òtítọ́ Ọlọ́run nípa ìwọ̀yá ìjà tí ẹ̀mí hàn lọ́nà geere. Irú ìfihàn otítọ́ bẹ́ẹ̀ kò lè wá láti ọ̀nà míràn bíkòṣe nípa ìmísí àtọ̀runwá Ọlọ́run.

Ìwé yìí yíò ṣí ojú ìmòye rẹ lótìítọ́ sí ìdí tí o kò fi tíì máa ní ìṣẹ́gun nínú àwọn ìwọ̀yá ìjà ti ẹ̀mí rẹ àti nínú ogun ayé rẹ. Ó sì tún



fi yé ọ, àwọn ọ̀nà tí à n tẹ̀lé láti jẹ́ aṣẹ́gun nínú ogunkógun tí í ṣe ti ẹ̀mí nínú ayé rẹ. Mo pe ìwé yìí ní kíkà fún gbogbo Krìstẹ́nì tí ó bá wù láti gbé ìgbé ayé Krìstẹ́nì aṣẹ́gun.

**Ọlálékan Ọ̀rẹ́gbẹ̀san**

# ÌFÁÀRÀ

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ onígbàgbọ́ n jìyà ní ìdákẹ́jẹ́, èṣù mú wọn ní ìgbèkùn, ó sì n yí wọn po nítorí tí wọn kò ní òye àwọn ìlànà ogun ti ẹ̀mí.

Nítòótọ́, ọ̀pọ̀ n gbàwẹ̀, wọ́n sì n gbàdúrà ṣùgbọ́n wọn kò rí èsì nítorí wọ́n kùnà láti mòye ìgbà àti bí a ti í lo àwọn ohun ìjà ti ẹ̀mí àti àwọn ilànà tí ó kápá ìwọ̀yá ìjà ti ẹ̀mí.

Ìwé yìí tí a kọ lábẹ́ ipa àti ìtọ́ní Ẹ̀mí Mímọ́. Gbogbo ìwé mímọ́ ni ó ní ìmísí Ọlọ́run tí ó sì ni èrè fún ẹ̀kọ́, fún ìbániwí, fún ìtọ́ni, fún ìkọ́ni tí ó wà nínú òdodo." 2 Tim 3:16, yíò mu wá sí kedere, àwọn ilànà ìpìlẹ̀ tí ó jọba lórí ogun ti ẹ̀mí àti ọ̀nà láti máa jẹ́ aṣẹ́gun ní gbogbo ìgbà.

Mo gbàdúrà pé ìwé yìí yíò ṣe ìdàgbàsókè èmí rẹ ní ànfàání àti pé kí Ọlọ́run kí ó bùkún fún ọkàn rẹ bí o ti n kà á ní orúkọ Jésù. Àmín.



# ÌMỌRÍRÌ

Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run alágbára nípasẹ̀ Olúwa wa Jésù Krístì, ẹni tí ó ti fún mi ni ore-ọ̀fẹ́ láti kọ ìwé yìí. Mo kọ ìwé yìí ní ìmúṣẹ ìpè àti èròngbà Ọlọ́run fún ayé mi, nítorí náà mo fi ògo, ọlá àti ọlánlá fún Òun nìkan, nítorí Òun nìkan ni ó yẹ láti yìn àti láti júbà, Òun ni n ó sì máa yìn títí láí nínú ayé mi. Àmín.

N ò le ṣàì dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run alágbára fún ọkọ ìyanu, onífẹ̀ẹ́ àti olùtọ́jú tí Ọlọ́run fi fún mi, ẹnití ó ti fi gbogbo ìgbà wà níbẹ̀ fún mi gẹ́gẹ́bí baba, ọ́rẹ́ àti ẹ̀gbọ́n, Alàgbà Julius Olúkáyọ̀dé Owólabí. Mo yin Ọlọ́run fún ore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ lórí ayé yin ọkọ mi ọ̀wọ́n, mo nífẹ̀ ẹ́ yín púpọ̀.

Mo tún dúpẹ́ lọ́wọ́ olùṣọ́-àgùntàn mi, Olùṣọ́-àgùntàn I.G. Fákúnlé, ẹniti mo mọ rírì àwọn ẹ̀kọ́ wọn gidigidi. Wọ́n jẹ́ olùkọ́ òtítọ́, wọ́n n kọ́ni ní ọ̀nà sí ibùgbé

wa tí í ṣe ọ̀run. Olúwa ti lo àwọn ẹ̀kọ́ yín láti tó mi àti láti fi ọ̀rọ̀ rẹ sí mi múlẹ̀. Bàbá, ẹ sọ̀wọ́n, mo sì dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún ore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ lórí ayé yín.

Ko sí bí mi o ṣe lè ṣe àìdúpé lọ́wọ́ bàbá mi nínú Olúwa, arákùnrin Solomon Ọlálékan Ọ̀rẹ́gbẹ̀san, ọ̀dọ́mọkùnrin tí ó ní àwọn àmúyẹ bàbá tòótọ́. Ó fi ara àti àkókò rẹ̀ sílẹ̀ láti pé kí Ọlọ́run kí o lò fún ayé mi. Arákùnrin Lékan, ẹ gba Ọlọ́run láàyè láti lò yín fún ìmúdàgbà mi pẹ̀lú sùúrù àti òye. Kò su yín láti máa bu omi rin mí nínú ẹ̀mí àti nípa ti ara. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún ayé yín.



# Ọ̀RỌ̀ ÌṢÁÁJÚ

Nígbàtí ènìyàn sọnù nínú ọgbà Edẹ́nì, lẹ́yìn tí ó ṣẹ̀ sí Ọlọ́run, ó sọnù nínú ẹ̀mí bákannáà, kì í ṣe nínú ara nìkan. Ènìyàn kọ́kọ́ kú nínú ẹ̀mí lẹ́yìn ṣíṣe àìgbọràn sí Ọlọ́run, kí ó to farahàn nínú ara.

> "3. Ṣùgbọ́n nínú èso igi nì tí ó wà láàrin ọgbà Ọlọ́run ti wípé, ẹ̀yin kò gbọdọ̀ jẹ nínú rẹ̀, bẹ̃ni ẹ̀yin kò gbọdọ̀ fọwọ́ kàn án, kí ẹ̀yin kí ó má ba kú. 4.Ejò náà sì wí fún obìnrin náà pé, ẹ̀yin kì yíò kú ikú kíkú kan. 5.Nítorí Ọlọ́run mọ̀ pé, ní ọjọ́ tí ẹ̀yin bá jẹ́ nínú rẹ̀, nígbànáà ni ojú yín yíò là, ẹ̀yin ó sì dà bí Ọlọ́run, ẹ ó mọ rere àti búburú. 6.Nígbàtí obìnrin náà sì ri pé, igi náà dára ní jíjẹ, àti pé, ó sì dára fún ojú, àti igi tí a í fẹ́ láti mú ni gbọ́n, ó mú nínú èso rẹ̀ ó

sì jẹ, ó sì fún ọkọ rẹ̀ pẹ̀lú rẹ̀, òún sì jẹ. 7. Ojú àwọn méjèèjì sì là, wọ́n sì mọ̀ pé àwọ́n wà ní ìhòhò; wọ́n sì gán ewé ọ̀pọ̀tọ́ pọ̀, wọ́n sì dá ibàntẹ́ fún ara wọn." Gen 3:3-7.

Nígbàtí ènìyàn bá kú nípa ti ara, yálà nípa ìjàmbá tàbí ọ̀nà mìírán, ohun kan máa n ṣẹlẹ̀. Ojú rẹ̀ yíò padé nípa ti ara, ṣùgbọ́n yíò ṣí sílẹ̀ nípa ti ẹ̀mí. Èyí jẹ́ látàri wípé, ẹ̀yà ara ti kú. Nítorí náà, ẹ̀mí ènìyàn tí ó n gbé nínú ara ni yíò jí dìde.

Bẹ́ẹ̀ náà ni, nígbàtí ẹ̀mí Ọlọ́run nínú ènìyàn bá ti kú, ojú rẹ̀ lè ṣí sílẹ̀ nínú ara, ṣùgbọ́n òún ti lọ nínú ẹ̀mí.

Èyí ni ó ṣẹlẹ̀ sí Ádámù àti Efà nínú ọgbà ní gẹ̀rẹ́ tí èṣù tàn wọ́n jẹ.

"3. Ejò náà sì wí fún obìnrin náà pé, ẹ̀yin kì yíò kú ikú kíkú kan. 4. Nítorí Ọlọ́run mọ̀ pé ní ọjọ́ tí ẹ̀yin bá jẹ nínú rẹ̀, nígbànáà ni ojú yín yíò là, ẹ̀yin ó sì dàbí Ọlọ́run, ẹ ó mọ rere àti búburú." Gen 3:4-5.





Èṣù mọ̀ dájú wípé ẹ̀mí ni ó n darí ara, àti wípé bí ohun gbogbo bá wà ní pípé nínú ẹ̀mí, ara kò ri ọgbọ́n dá ju pé kí ó ṣiṣẹ́ pọ̀ kí ó sì mú àwọn àbájáde ohun tí ó n ṣẹlẹ̀ nínú ẹ̀mí kí ó wá síta. Ìlàkàkà èṣù lójojúmọ̀ lórí Krístẹ́nì ni láti wó wa palẹ̀ láti inú ẹ̀mí wá sí inú ara, kí òun ba lè mú wa ṣe lòdì sí ìfẹ́ Ọlọ́run.

Nítorí wípé, nínú ara, a kò ní agbára láti ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run. Nígbàtí a bá wà nínú ara, à n ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́bí òfin ti ara àti òfin ti ayé yìí. "5. Nítorí àwọn tí ó wà nípa ti ara, wọn a máa ro ohun ti ara; ṣùgbọ́n àwọn tí ó wà nípa ti Ẹ̀mí, wọn a máa ro ohun ti Ẹ̀mí. 6. Nítorí èrò ti ara ikú ni; ṣùgbọ́n èrò ti Ẹ̀mí ni ìyè àti àláfíà: 7. Nítorí èrò ti ara ọ̀tá ni sí Ọlọ́run: nítorí kì í tẹríba fún òfin Ọlọ́run, òun kò tilẹ̀ le ṣe é. 8. Bẹ́ẹ̀ni àwọn tí ó wà nínú ti ara, kò le wu Ọlọ́run." Rom 8:5-8.

Èṣù mòye wípé, nígbàtí o bá wà nínú ẹ̀mí, o wà nínú àyíká tí òun kò ní àkósò lórí. Nínú ẹ̀mí, ó wà ní àkósò, Ọlórun sì wà ní àkósò pẹ̀lú.

"Ẹ̀mí ni Ọlọ́run: àwọn ẹnití n sìn Í kò lè ṣe aláìsìn Í ní ẹ̀mí àti ní òtítọ́. " Jòhánù 4:24

Ṣùgbọ́n nínú ara, èṣù ni ó n ṣàkósò.

"2. Nínú èyítí ẹ̀yin ti n rìn gẹ́gẹ́ bí ipa ti ayé yìí, gẹ́gẹ́bí aláṣẹ agbára ojú ọ̀run, ẹ̀mí tí n ṣiṣẹ́ nísisìyí nínú àwọn ọmọ aláìgbọràì; 3. Nínú àwọn ẹnití gbogbo wa pẹ̀lú ti wà rí nínú ìfẹ́kúfẹ̀ ara wa, à n mú ìfẹ́ ti ara àti tinú ṣẹ; àti nípa ẹ̀dá àwa sì jẹ́ ọmọ ìbínú, gẹ́gẹ́ bí àwọn ìyókù pẹ̀lú. 4. Ṣùgbọ́n Ọlọ́run, ẹnití íṣe ọlọ́rọ̀ ní àánú, nítorí ìfẹ́ nlá rẹ̀ tí ó fi fẹ́ wa, 5. Nígbatí àwa tilẹ̀ ti kú nítorí ìrékọjẹ́ wa, ó sọ wá di àyè pẹ̀lú Krístì (ore-ọ̀fẹ́) tí a ti fi gbà yín là." Efésù 2:2-5

"Nítorí ohun gbogbo tí n bẹ ní ayé, ìfẹ́kúfẹ̀ ara, àti ìfẹ́kúfẹ̀ ojú, àti irera





ayé, ìfẹ́ ti Baba kò sí nínú rẹ̀" 1 Jòhánù 2:16

Àwọn ibi ìwé mímọ́ wọ̀nyí fi yé wa yéké wípé èṣù n làkàkà lórí wa lójojúmọ́ láti mú wa kúrò ní àyíká tí Ọlọ́run (ipa ti ẹ̀mí) wá sí àyíká tirẹ̀ (ara) kí òún ba lè yí po, mú ní ìgbèkùn, pa àti parun.

"Ẹ máa wà ní àìrékọjá, ẹ máa ṣọ́ra; nítorí Èṣù, ọ̀tá yín, bí kìnìún tí n ké ramúramù, ó n rìn káàkiri, ó n wá ẹnití yíò pajẹ kiri:" 1 Pétérù 5:8

Àwọn àlàyé àti ẹsẹ bíbélì tí a ti ṣe ṣíwájú yìí fi yéni yéké wípé ogun àti ìwọ̀yá ìjà ìgbàgbogbo n ṣẹlẹ̀ láàrin ènìyàn àti èṣù. A lè ri wípé ogun yìí jẹ́ ti ẹ̀mí, kì í sì í ṣe ti ara. A sì ti ri wípé èṣù ní àwọn ọ̀nà àti bájà àti láti dojúkọ àwọn onígbàgbọ́, èyí tí ó n mú wa kúrò nínú ẹ̀mí wa sí inú ara. Ó n gbìyànjú láti yí ibùdó ìjà kúrò ní ibití òun kò ti ní àkóso lọ sí ibití ó ti n ṣàkósò.

"Nítorípé kìí ṣe ẹ̀jẹ̀ àti ẹran-ara ni àwá n bá jìjàkadì, ṣùgbọ́n àwọn ìjòyè, àwọn ọlọ́lá, àwọn aláṣẹ ibi

òkùnkùn ayé yìí, àti àwọn ẹ̀mí búburú ní ojú ọ̀run." Efésù 6:12.

Tí èṣù bá ní ọ̀nà láti bá ọ jà, ìwọ náà gbọ́dọ̀ mọ̀ wípé ọ̀nà gbọ́dọ̀ wà láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run fún ọ láti dojú ìjà kọ èṣù náà.

" Nítorípé kìí ṣe ẹ̀jẹ̀ àti ẹran-ara ni àwá n bá jìjàkadì, ṣùgbọ́n àwọn ìjòyè, àwọn ọlọ́lá, àwọn aláṣẹ ibi òkùnkùn ayé yìí, àti àwọn ẹ̀mí búburú ní ojú ọ̀run. 13.Nítorínáà ẹ gbé gbogbo ìhámọ́ra Ọlọ́run wọ̀ kí ẹ̀yin kí ó lè dúró tiri sí ọjọ́ ibi, nígbàtí ẹ̀yín bá sì tí ṣe ohun gbogbo tán, kí ẹ sì dúró." Efésù 6:12-13.

Àwọn ọ̀nà yìí, láti ja àwọn ogun ìgbà dé ìgbà tí a ní pẹ̀lú èṣù àtí àwọn ìlànà fún àti lò wọ́n; kí o ba lè máa jẹ́ aṣẹ́gun, bí ó ti wù kí ogun náà kí ó le tó, ni ẹ̀mí Ọlọ́run ti mísí mi, tí ó sì darí mi láti mú papọ̀ sínú ìwé yìí.

Ní ìkoríta yìí, máà fẹ́ kí o gbàdúrà yìí kí o tó tẹ̀síwájú ní kíkà àti ṣíṣe àṣàrò lórí ìwé yìí.





“Mo bẹ́bẹ́ fún ẹ̀jẹ̀ Jésù Krístì sórí ẹ̀mí, ọkàn àti ara mi. Mo tú ẹ̀mí mi sílẹ̀ lọ́wọ́ ibi gíga èṣù tí kò ní gbà mí lááyè láti rí tàbí gba ìfihàn otítọ́ Ọlọ́run sí mi nípasẹ̀ ìwè yìí. Olúwa, ṣí ọkàn mi payá àti ojú ẹ̀mí mi láti rí òtítọ́ àti àwọn ìfihàn tí o ní fún mi nípasẹ̀ ìwé yìí, kí o sì fi ẹsẹ̀ mi lé ibi tó ga. O ṣeun Olúwa, ní orúkọ Jésù Krístì. Àmín.”

## KÍNNI OGUN?

1. Ogun jẹ́ ọ̀nà tí ènìyàn n gbà láti gba ẹ̀tọ́ tàbí ohun tí ó jẹ́ tirẹ̀ padà lọ́wọ́ àwọn ẹlòmíràn.
2. Ogun jẹ́ rògbòdìyàn, ìjà tàbí ìwọ̀yá ìjà pẹ̀lú agbára tí ó dojúkọni láti fi àjùlọ hàn tàbí gba ẹ̀tọ́ tàbí ohun ìní ẹni padà.

Ènìyàn lè bá ara rẹ̀ ja ogun nígbàtí ó bá mọ̀ wípé ohun tí ó n ṣe kò dára. Bákannáà, ó lè bá ẹlòmíràn jà, ṣùgbọ́n nínú kíkọ ìwé yìí, à n sọ nípa bíbá èṣù jà

láti gba gboogb ohun tí ó ti gbà lọ́wọ́ rẹ padà.

"5. Mo sì gbọ́ angẹ́lì ti omì ni wípé, Olódodo ni Ìwọ Ẹni Mímọ́, ẹnití ó n bẹ, tí ó sì ti wà, nítorítí ìwọ ṣe ìdájọ́ báyìí. 6. Nítorítí wọ́n ti ta ẹ̀jẹ̀ àwọn ènìyàn mímọ́ àti ti àwọn wòlí sílẹ̀, ìwọ sì fi ẹ̀jẹ̀ fún wọn mu; èyíyìí ni ó yẹ wọ́n. 7. Mo sì gbọ́ pẹpẹ n ké wípé, Bẹ́ni, Ọlúwa Ọlọ́run Ọlódùmarè, òtítọ́ àti òdodo ni ìdájọ́ rẹ. 8. Ẹ̀kẹrin sì tú ìgò tirẹ̀ sórí òrùn, a sì yọ̀da fún u láti fi iná jó ènìà lára. 9.A sì fi oru nlá jó àwọn ènìyàn lára, wọ́n sì sọ̀rọ̀ òdì sí orúkọ Ọlọ́run, ẹnití ó ni agbára lórí ìyọnu wọ́nyí: wọn kò sì ronúpìwàdà láti fi ògo fún u. 10. Ẹ̀karún sì tú ìgò tirẹ̀ sórí ìtẹ́ ẹranko náà; ilẹ̀-ọba rẹ sì ṣókùnkùn; wọ́n sì ngé ahọ́n wọn jẹ nítorí ìrora. 11. Wọ́n sì sọ̀rọ̀ òdì sí Ọlọ́run ọ̀run nítorí ìrora wọn àti nítorí egbò wọn, wọ̀n kò sì ronúpìwàdà ìṣẹ́ wọn. 12. Èkefà sì tú ìgò tirẹ̀ sórí odò nlá





Eufrate; omi rẹ̀ sì gbẹ, kí á le pèsè ọ̀nà fún àwọn ọba àti ìla-òrùn wá. 13.Mo sì rí àwọn ẹ̀mí àìmọ́ mẹ́ta bí ọ̀pọ̀lọ́, wọ́n ti ẹnu drágónì náà àti ẹnu ẹranko náà àti ẹnu wòlí èké náà jáde wá. 14. Nítorí ẹ̀mí èṣù ni wọ́n, tí n ṣe iṣẹ́ ìyanú, àwọn tí n jáde lọ sọ́dọ̀ àwọn ọ̀ba gbogbo ayé, láti gbá wọn jọ sí ogun ọjọ́ nlá Ọlọ́run Olódùmarè." Ìfihàn 16:5-14

Láìsí ogun, kò lée sí aṣẹ́gun, èyí ní wípé ìṣẹ́gun n wà lẹ́yìn ìwọ̀yá ìjà tàbí ìjagun.

"Ẹ̀yin kò mọ̀ pé àwọn tí nsáré ìje, gbogbo wọn ní n sáré nítòótọ́, ṣùgbọ́n ẹnìkan ní n gba èrè náà? Ẹ sáré bẹ́ẹ̀, kí ẹ̀yin kí ó lè ri gbà." 1 Kor 9:24

A wà ní ìjàkadì ìgbà dé ìgbà pẹ̀lú ọ̀tá, èṣù àti alákòso ibi òkùnkùn ayé yìí.

"Nítorípé kìí ṣe ẹ̀jẹ̀ àti ẹran ara ni àwá n bá jìjàkadì, ṣùgbọ́n àwọn ìjòyè, àwọn ọlọ́lá, àwọn aláṣẹ ibi

òkùnkùn ayé yìí, àti àwọn ẹmí búburú ní ojú ọ̀run." Efésù 6:12

Nítorí náà, ní ìwọ̀n ìgbà tí a sì n gbé inú ayé yìí, kí á tó lọ sílé, a gbọ́dọ̀ ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn òfin àti ìlànà tí ọ̀gá ti ìjọba ìmọ́lẹ̀ tí a jẹ́ tirẹ̀, kí á ba lè gbé inú ayé òkùnkùn yìí.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó jẹ́ ìgbà dé ìgbà, ó sì gbónà janjan, a ní ìdánilójú ìṣẹ́gun nítorí pé bàbá wa ni ó n darí ogun yìí.

"Nkan wọ̀nyí ni mo ti sọ fún un yín tẹ́lẹ̀, kí ẹ̀yin kí ó lè ní àláfíà nínú mi. Nínú ayé, ẹ̀yin o ní ìpọ́njú; ṣùgbọ́n ẹ túјúká; mo ti ṣẹ́gun ayé." Jòhánù 16:33

## KÍNNI AYÉ RẸ?

Ayé jẹ́ wíwà láàyè, ó jẹ́ ìwọ̀n ìgbà tí a wà, ó jẹ́ gbígbé ìgbé ayé. Ayé jẹ́ èyà pàtàkì nínú ìṣẹ̀dá. Gbígbé ayé kò ní ìtumọ̀ mọ́ bí kò bá ti mú ìdí tí o fi wá ṣẹ, nígbà tí a bá ti fi àwọn ètò gbógì fún ìgbé ayé rẹ dù ọ́. Ètò sí





àlàáfía, iṣẹ́ rere, ayọ̀, ìdùnnú, àlùyọ, ìbísíi àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, nígbà náà ni ìdí tí o fi wà láàyè ti kú díẹ̀, ayé gbígbé kò sì ní ìtumọ̀.

O ní ẹ̀tọ́ láti wà, kí o sì wà láàyè, ṣùgbọ́n èṣù sọ wípé ìwàláàyè rẹ gbọ́dọ̀ wà lábẹ́ àkósò àti ìjọba òun. Mo so wípé àkókò ti tó fún ọ láti so fún èṣù wípé o mọ ẹni tí ìwọ́ gbàgbọ́ àti wípé nítorí tí olùdándè rẹ n bẹ láàyè, ìwọ́ yíò ye. Àmín.

"Ẹ̀mí gígùn ni èmi ó fi tẹ́ ẹ lọ́rùn, èmi ó sì fi ìgbàlà mi hàn án." Orin Dáfídì 91:16.

ORÍ KÌNNÍ

# MÍMÒYE ÌJAGUN TI ẸMÍ

Ohun ti kò bá yé ọ, o kò lè mọ rírì rẹ̀, o sì ní láti mòye wípé, àwọn ogun ti ẹ̀mí wà nínú ayé wa ojojúmọ́. O ní láti mòye bí a ti í ja àwọn ogun wọ̀nyí àti ọ̀nà tí a fi í ṣẹ́gùn nígbàgbogbo.

> "3.Nítorípé bí àwá tilẹ̀ nrìn ní ti ara, ṣùgbọ́n àwa kò jagun nípa ti ara: 4.(Nítorí ohun ìjà wa kìí ṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó ní agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀;) 5.Àwá n sọ gbogbo èrò kalẹ̀, àti gbogbo ohun gíga tí n gbé ara rẹ̀ ga sí ìmọ̀ Ọlọ́run, àwá sì n di gbogbo èrò ní ìgbèkùn wá sí ìtẹ́ríba fún Krístì; 6.Àwá sì ti múra tan láti gbẹ̀san





> gbogbo àìgbọ̀ràn, nígbàtí ìgbọràn yín bá pé." 2 Kor 10:3-6

Ibi ìwé mímọ́ tó wà lókè yìí fún wa ní òye wípé ogun ẹ̀mí n nbẹ. Ó wípé:

> "nítorí pé bí àwa tilẹ̀ n rìn ní ti ara, àwa kò sí ní ti ara…"

Èyí túmọ̀ sí wípé, bí a bá tilẹ̀ wà nínú ẹ̀ya ara tí a sì n rìn tàbí ṣe ọ̀pọ̀ ohun nípa ti ara, tí a le rí kí á sì fi ọwọ́ kàn, ṣùgbọ́n irú ogun tí à n jà kì í ṣe nípa ti ara. Kìí ṣe ogun pẹ̀lú ẹni tí ó lè rí tàbí fi ọwọ́ kàn. Ogun náà kìí ṣe pẹ̀lú ọkọ rẹ, aya rẹ, àwọn ará ilé rẹ, àwọn ẹbí rẹ, ọ̀gá rẹ, alájọṣiṣẹ́ rẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ti o lérò wípé wọ́n n bá ọ wọ̀yá ìjà. Àwọn agbára ẹ̀mí tí n ṣe okùnfà ìhùwà àti ìṣesí sí ọ.

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, a gbàgbé otítọ́ yìí tàbí a gbàgbọ́ síi wípé àwọn tí ó wà ní àyíká wa ni ọ̀tá wa, nítorí bí èṣù ti ṣe ṣàṣeyọrí ní yíyí wọn po lòdì sí wa. Rárá! Kò rí bẹ́ẹ̀. Kì í ṣe ọ̀gá rẹ tàbí alájọṣiṣẹ́ rẹ ní ibi iṣẹ́ ni ìṣòro, èṣù ni. O ní láti mọ̀ wípé èṣù n fẹ́ kí

o gbàgbọ́ pé àwọn ènìyàn tí n bẹ ní àyíká rẹ ni ìṣòro tí o ní, kí akitiyan rẹ láti dojú kọ ìṣòro náà àti orísun rẹ̀ lè jẹ́ àṣedànù.

Ibi ìwé mímọ́ tó wà lókè nínú 2 Kor 10:4, jẹ́ kí ó yé wa pẹ̀lú wípé àwọn ohun ìjà wà fún wa láti jà, àwọn ohun ìjà wọ̀nyí kì í ṣe ti ara bí ìbọn, ọ̀kọ̀ tí a le ta tí a sì lè fi ọwọ́ kàn, ṣùgbọ́n wọ́n jẹ́ ohun ìjà ti ẹ̀mí.

> “Nítorí ohun ìjà wa kìí ṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó ní agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀;" 2 Kor 10:4

Apá kejì ẹsẹ̀ ìkẹrin yìí jẹ́ kí ó yé wa bí a tií lo àwọn ohun ìjà ti ẹ̀mí wọ̀nyí àti ohun tí a n fi wọ́n dojúkọ.

Ẹsẹ náà sọ wípé, àwọn ohun ìjà wọ̀nyí kìí ṣe ìbọn àti ọfà ti ara, èyí tí à n lò pẹ̀lú ọwọ́, ṣùgbọ́n wọ́n jẹ́ ìbọn àti ọfà ti ẹ̀mí, èyí tí à n lò nípasẹ̀ Ọlọ́run.

Nípa ti ara, ọta ni agbára ìbọn, ọfà sì ni agbára ọ̀kọ̀. Ṣùgbọ́n nínú ẹ̀mí, Ọlọ́run ni ọta fún ìbọn àti pẹ̀lú ọfà fún ọ̀kọ̀.





Ọlọ́run ni okun fún gbogbo ohun ìjà ti ẹ̀mí tí a le lò. Nítorí náà, nípasẹ̀ Ọlọ́run ni a le lo gbogbo ohun ìjà ti ẹ̀mí kí ó ba lè ní ipa.

> “Olùbùkún ni Olúwa àpáta mi, ẹnití ó kò ọwọ́ mi ní ogun, àti ìka mi ní ìjà." Orin Dáfídì 144:1

> "Ó kọ́ ọwọ́ mi ní ogun jíjà, tóbẹ́ẹ̀ tí apá mi fa ọrún idẹ." Orin Dáfídì 18:34

> "Ó kọ́ ọwọ́ mi ní ogun jíjà; tó bẹ́ẹ̀ tí apá mi fa ọrún idẹ." 2 Sam 22:35

Ìwé mímọ́ tún sàlàyé wípé àwọn ohun ìjà tí ẹ̀mí wọ̀nyí, bí a bá lò wọ́n nípa Ọlọ́run, ni wọ́n dojúkọ àwọn ibi gíga, wọ́n sì n wó palẹ̀ gbogbo ìrònú àti ohun gíga tí ó gbé ara rẹ̀ ga lòdì sí ìmọ̀ Ọlọ́run, àti pẹ̀lú mímú wa sí inú ìdè, gbogbo èrò sí ìgbọ́ràn sí Krístì.

O lè béèrè, níbo ni a ti dárúkọ èṣù nínú gbogbo ìwọ̀nyí? A lè má dárúkọ

"èṣù" sùgbọ́n ọ̀nà tí èṣù ti yà láti gbà láti bá ọ jà àti láti bì ọ́ ṣubú ní àwọn ohun tí a dárúkọ, àwọn wọ̀nyí sì ni o ní láti dojúkọ

Bí o o ṣe jà láti pa ejò kọ́ ni o ó ṣe jà láti pa ọ̀ni tàbí kìnìún. Bí èṣù bá yàn láti fi ara hàn bí ejò láti bá ọ jà, ó jẹ́ pé o gbọ́dọ̀ jà pẹ̀lú òye bí a tií pa ejò kí o ba lè borí.

Bí èṣù bá ti yàn láti dojú kọ ọ́ bi ibi gíga, o ni láti mòye ohun tí ibi gíga jẹ́ àti bí a tií wó wọn palẹ̀, kí o sì jẹ́ aṣẹ́gun lórí èṣù.

Olùfẹ́, o gbọ́dọ̀ mòye kí o sì gbà ní ìkoríta yìí pé, **òtítọ́** ni wípé ogun ayé wà. Àwọn kókó wọ̀nyí pẹ̀lú jẹ́ òtítọ́ nípa ogun ayé.

1. Ogun ayé bẹ̀rẹ̀ láti inú oyún. Kì í ṣe gbogbo ọmọ tí a lóyún rẹ̀ ni wọ́n jẹ́ bíbí. Wípé a bí ọ, o sì wà láàyè fihàn wípé o ti borí ogun àkọ́kọ́.

" Ìwọ ni a ti fi mí lé lọ́wọ́ láti inú ìyá mi wá: ìwọ ni Ọlọ́run mi láti inú ìyá mi wá." Orin Dáfídì 22:10.





"Ọwọ́ rẹ li a ti fi gbé mi dúró láti inú wá: ìwọ ni ẹnití ó mú mi jáde láti inú ìyá mi wá: nípasẹ̀ rẹ ni ìyìn mi wà nígbàgbogbo." Orin Dáfídì 71:6

"Báyìí ni Olúwa wí ẹnití ó dá ọ, tí ó mọ̀ ọ́ láti inú wá, tí yíò sì ràn ọ́ lọ́wọ́; Má bẹ̀rù, ìwọ Jákọ́bù, ìránṣẹ́ mi; àti ìwọ Jésúrúnì tí mo yàn." Isaiah 44:2

"Nítorítí kò pa mí sínú ìyà mi, tóbẹ́ẹ̀ kí ìyá mi di isà mi, kí ó lóyún mi láíláí." Jere 20:17.

"Ṣùgbọ́n nígbàtí ó wu Ọlọ́run, ẹnití ó yà mí sọ́tọ̀ láti inú ìyá mi wá, tí ó sì pè mí nípa ore-ọ̀fẹ́ rẹ̀." Gal 1:15.

2. Ogun náà kò ní nnkan ṣe pẹ̀lú ibi tí ó gbé wá. Ogun náà n ṣẹlẹ̀ níbi gbogbo, ibi yówù kí o wà.

3. Awọn ohun ìjà wa jẹ́ ti ẹ̀mí, wọn kì í ṣe ti ara. "Nítorí ohun ìjà wa kì í ṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó ní agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀;" 2 Kor 10:4

4. Awọn ohun ìjà wa ni a ti fi fún wa."Kíyèsí i, èmí fun yín ní àṣẹ láti tẹ ejò àti àkekèé mọ́lẹ̀, àti lòrí gbogbo" agbára ọ̀tá: kò sì sí ohunkan bí o ti wù kí o ṣe, tí yio pa-nyín-lára. Lúkù 10:19

5. Ní kété ti o bá ti fi ayé rẹ fún Krístì, o ti wà nínú ọmọ ogun Ọlọ́run. “Ṣùgbọ́n iye àwọn tí ó bá gbàá, àwọn ni ó fi agbára fún láti di ọmọ Ọlọ́run, àní àwọn náà tí ó gba orúkọ rẹ̀ gbọ́." Jòhánù 1:12-13

6. O ní àtìlẹyìn ọ̀run nínú ogun ayé. "Dáfídì sì fi ọwọ́ rẹ̀ sínú àpò, ó sì mú òkúta kan láti inú ibẹ̀ wá, ó sì fi í, ó sì bá Fílístínì náà níwájú, òkúta náà sì wọ inú agbárí rẹ̀ lọ, ó sì ṣubú dojúbolẹ̀." 1Sam 17:49

7. Ìdánilójú ààbò n bẹ fún ọ lọ́wọ́ ìdojúkọ ọ̀tá."Wípé, ẹ má ṣe fi ọwọ́ kan ẹni-òróró mi, ẹ má sì ṣe àwọn wólì mi ní ibi." 1Kro 16:22.

“Pé, Ẹ má ṣé fi ọwọ́ kan ẹni-òróró mi kí





ẹ má sì ṣe àwọn wòlí mi ní ibi." Orin Dáfídì 105:15.

8. Ọlọ́run, Bàbá rẹ ti ṣètò rẹ fún ìṣẹ́gun tẹ́lẹ̀. "Èmí ti lé àwọn ọ̀tá mi, èmí sì bá wọn: bẹ́ẹ̀ni èmi kò padà sẹ́hìn títí a fi run wọ́n." Orin Dáfídì 18:37.

"Èmí ti lépa àwọn ọ̀tá mi, èmí sì run wọ́n; èmi kò pẹ̀hìndà títí èmí fi run wọ́n." 2 Sam 22:38.

9. Gbogbo ènìyàn tí ó wà nínú Krístì ni ó wà nínú ogun yìí, bí ó ti wù kí ó kéré . “Lákòókò náà ni Jésù dáhún, ó sì wípé, Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ Baba, Olúwa Ọlọ́run òun ayé, nítorítí ìwọ́ pa nkan wọ̀nyí mọ́ kúrò ní ojú àwọn ọlọgbọ́n àti amòye, iwọ́ sì fi wọ́n hàn fún àwọn ọmọ-ọwọ́." Matt 11:25.

10. Àṣalẹ́ ni à n ja ọ̀pọ̀ àwọn ogun wọ̀nyí. "Ó sì ku Jákọ́bù nìkan; ọkùnrin náà sì n bá a jìjàkadì títí ó fi di àfẹ̀mọ́júmọ́. “ Gen 32:24.

11. Bí dídé Krístì ṣe n súnmọ́ sí ni ogun náà n gbóná si. "Nítorí ẹ̀mí èṣù ni wọ́n,

tí n ṣe iṣẹ́-ìyanu, àwọn tí n jáde lọ sọ́dọ̀ àwọn ọba gbogbo ilẹ̀ ayé, láti gbá wọn jọ sí ogun ọjọ́ nlá Ọlọ́run Olódùmarè." Ìfihàn 16:14

12. Ohunkóhun tó bá n ṣẹlẹ̀ nípa ti ara jẹ́ ìyókù ohun tí ó ṣẹlẹ̀ nínú ẹ̀mí.

13. Inú ọkàn ni ibùdó ìjà yìí, ibi tí ìjà náà ti n wáyé. "Tani ó ni òṣì? Tani ó ni ìbànújẹ́? Tani ó ni ìjà? Tani ó ni asọ̀? Tani ó ni ọgbẹ́ láìnìdìí, tani ó ni ojú pípọ́n." Òwe 23:19

14. Ní kété tí a bá ti mú ọkàn rẹ lẹ́rú, ibi gíga ti di kíkọ́ nìyẹn.



## ORÍ KEJÌ

# IBI GÍGA

## KÍNNI IBI GÍGA

Ibi gíga jẹ́ ibi tí a dì ní ìhámọ́ra tàbí ibi odi tí èṣù kọ́ láti gbé ara rẹ̀ ga lòdì sí ìmọ̀ Ọlọ́run nínú ayé rẹ. Ibi gíga jẹ́ ohunkóhun tí ó dá ọ gúnlẹ̀ lòdì sí ìfẹ́ rẹ̀.

Àwọn ibi gíga máa n jà ọ́ lólè àwọn ìbùkún Ọlọ́run. Wọ́n n jani lólè ìṣẹ́gun tí Ọlọ́run ti fi dáni lójú nínú ogun ayé.

Kì í ṣe wípé a máa n gbé ibi gíga wọ̀. Ẹ̀mí ènìyàn le wà láàyé tàbí kí ó kú. Bí a bá gba Krístì gẹ́gẹ́bí Olúwa àti Olùgbàlà, ẹ̀mí wa wà láàyè. Ẹnikẹ́ni tí kò bá tíì ṣe ìpinnu nlá yìí láti gba Krístì, ni òkú ẹ̀mí. Irú aláìgbàgbọ́ bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú òkú ẹ̀mí, lè jẹ́ ẹni tí ó jọ ara rẹ̀ lójú tàbí kí èṣù máa gbé inú rẹ̀, tí ó fi kọ̀ láti ṣe irú ìpinnu bẹ́ẹ̀ láti tẹ̀lé

Jésù. Ohun tí à n fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ níbí yìí ni wípé, kìkìdá àwọn tí kò tíì gba Jésù sínú ayé wọn ni ó ní ààyè nínú ọkàn wọn fún èṣù láti gbé.

Èṣù kò lè gbé ọmọ Ọlọ́run tí ó ti di àtúnbí wò mọ́. Ṣùgbọ́n yàtọ̀ sí kí èṣù ma gbé inú ayé ẹni, onígbàgbọ́ lè wà lábẹ́ ibi gíga. Èṣù mọ wípé òun kò lè gbé Krístẹ́nì wọ̀, nítorí náà ó n wá láti yí wa po nípasẹ̀ àwọn ohun tí a ti gbà láàyè sínú ọkàn wa. Àwọn wọ̀nyí sì ni àwọn ibi tí a ti n kó wa ní ìgbèkùn láti ṣe ìfẹ́ sàtánì.

**Báwo ni a ṣe n mọ ibi gíga?**

Ibi gíga lè jẹ́ ti ẹ̀mí tàbí ti ọgbọ́n orí. Àwọn àpẹẹrẹ èyí tí ó jẹ́ ti ẹ̀mí ni: ìbẹ̀rù, ìfẹ́kúfẹ̀, ìbínú, àárẹ̀, ìkúndùn, ìkọ̀sílẹ̀, ìṣekúṣe, àìní ìdáríjì àtí ìkorò.

Àwọn àpẹẹrẹ ibi gíga tí ó jẹ́ ti ọgbọ́n orí ni: asán, wọ̀bìà, ìgbéraga, ìfẹ́ ara ẹni, àfọkànsí àti èrò asán.

Ó ṣe pàtàkì kí ó yé wa wípé ìtúnbí máa n ṣẹlẹ̀ nínú ẹ̀mí wa. Bíbélì tan ìmọ́lẹ̀ si





wípé, àtúnbí ti ẹ̀mí jẹ́ ìmúpadàbò sípò ọkàn.

Àkọ́kọ́ rẹ̀ ṣẹlẹ̀ nígbàtí a bá gba Jésù. Ìkejì rẹ̀ jẹ́ ètò tí ó n ṣẹlẹ̀ bí ọjọ́ ṣe n gorí ọjọ́, èyí ni bí a bá yàn bẹ́ẹ̀.

> "Ṣùgbọ́n nínú ilé nlá, kìí ṣe kìkì ohun èlò wúrà àti ti fàdákà nìkan ni n be níbẹ̀, ṣùgbọ́n ti igi àti ti amọ̀ pẹ̀lú; àti òmíràn sí ọlá, àti omíràn sí àìlọ́lá. Bí ẹnikẹ́ni bá wẹ ara rẹ̀ mọ́ kúrò nínú wọ̀nyí, òún jẹ́ ohun èlò sí ọlá, tí a yà sí ọ̀tọ̀, tí ó sì yẹ fún ìlò baálé, tí a sì ti pèsè sílẹ̀ sí iṣẹ́ rere gbogbo." 2 Tim 2:20-21

Gbogbo Krístẹ́nì gbọ́dọ̀ ní àkókò kan nínú ayé wọn tí wọ́n pinnu láti gbé ìgbé ayé nínú ọ̀pọ̀ ohun rere. A fún wa ní ore-ọ̀fẹ́ láti yàn bóyá a fẹ́ jẹ́ Krìstẹ́nì aṣẹ́gun tàbí a kò fẹ́ jẹ́ bẹ́ẹ̀.

A lè yàn láti gbé ìgbé ayé Krìstẹ́nì tí ó kún fún ayọ̀, àláàfíà àti ìwà mímọ́. Tàbí kí á yàn láti gbé ìgbé ayé Krístẹ́nì tí ó kún fún ìkúndùn, ọgbẹ́ àtẹ̀yìnwá àti ìkùnà.

Nígbà tí a bá fi ara wa sílẹ̀ fún ìdánwò àti ẹ̀ṣẹ̀, a tú àwọn ipá òkùnkùn tí n pani sílẹ̀, a sì ṣí ọkàn wa sílẹ̀ fún ìjìyà ẹ̀mí òkùnkùn. Kì í ṣe wípé a ti di ẹrú ẹ̀ṣẹ̀ bẹ́ẹ̀ nìkan, ṣùgbọ́n ẹ̀ṣẹ̀ náà yíò mú ikú wá ní ìgbẹ̀yìn. Jésù wípé:

> "Jésù dá wọn lóhùn pé, Lóòtọ́ lóòtọ́ ni mo wí fun yín, ẹnikẹ́ni tí ó bá n dẹ́ṣẹ̀, òun ni ẹrú ẹ̀ṣẹ̀." Jòhánù 8:34

> "Ṣùgbọ́n olúkúlùkù ni à n dánwò, nígbàtí a bá fi ọwọ́ ìfẹ́kúfẹ̀ ara rẹ fà á lọ, tí a sì tan an jẹ. Njẹ́, ìfẹ́kúfẹ̀ náà nígbàtí ó bá lóyún, á bí ẹ̀ṣẹ̀,: àti ẹ̀ṣẹ̀ náà nígbàtí ó bá sì dàgbà tán, a bí ikú." Jákọ́bù 1:14-15

Sàtánì ni ó wà ní ìdí ìdánwò ènìyàn. Sàtánì àti àwọn ẹ̀mí òkùnkùn ni wọ́n parapọ̀ jẹ́ ìjọba òkùnkùn. Ẹni tí a dá ni sàtánì, nítorí náà, òun kì í ṣe ẹni tí ó le wà ní ibi gbogbo lẹ́ẹ̀kannáà, bí Ọlọ́run. Sàtánì kò lè wà ní ibi gbogbo ní ẹ̀ẹ̀kan, ó gbọ́kàn lé ìrànlọ́wọ́ àwọn ángẹ́lì ẹ̀mí





òkùnkùn rẹ̀ tí a lé sọ̀kálẹ̀ láti ọ̀run pẹ̀lú rẹ̀.

Nígbà kígbà tí ìdánwò bá wà láti dẹ́ṣẹ̀, ẹ̀mí búburú kan wà lẹ́hìn ìdánwò náà tí ó n gbìyànjú láti mú wa wọ inú ẹ̀ṣẹ̀ náà. Bí wọ́n bá rí wa mú láti ṣubú sínú ìdánwò náà àti láti ṣẹ̀, wọ́n ní àṣẹ àti ètò láti ní ìjọba nínú ọkàn wa.

"Bẹ́ẹ̀ni kí ẹ má ṣe fi àyè fún èṣù." Efésù 4:27.

Ó yé wa yéké láti ibi ìwé mímọ́ yìí wípé a lè fún èṣù ní ààyè ìjọba. Ẹsẹ yìí n tọ́ka sí ìbínú. Bí a bá ṣẹ̀ nínú ìbínú wa, nígbànáà ni a ti fún èṣù ní ààyè ìjọba. Èyí jẹ́ àpẹẹrẹ kan nínú bí ẹ̀ṣẹ̀ ṣe máa n sí ìlẹ̀kùn. Àwọn ọ̀nà púpọ̀ mìíràn wà tí ọ̀tá n lò láti ní ààyè ìjọba nínú ọkàn wa. Àwọn ààyè ìjọba wọ̀nyí, bí a kò bá jẹ́wọ́ wọn, kí á ronúpìwàdà, kí á sì kọ̀ wọ́n sílẹ̀, wọn ó di ibi gíga ní ìgbẹ̀yìn.

Àwọn ibi gíga bẹ́ẹ̀, bí a sì fi wọ́n sílẹ̀, wọn yíò dè wá pẹ̀lú ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ tí ẹ̀mí tí a kò rí, yíò sì mú ìparun wá sí ayé wa.

"Ẹ̀ṣẹ̀ ẹni-búburú ni yíò mú òun tìkararẹ̀, okùn ẹṣẹ̀ ara rẹ̀ ni yíò sì dì í mú." Òwe 5:22.


Bí ènìyàn bá ní ibi gíga nínú ẹ̀yà ayé rẹ̀, ọ̀kan nínú àwọn ohun méjì yìí yíò ṣẹlẹ̀.

1. Wọn ó ma dá ẹ̀ṣẹ̀ náà ní ìgbà dé ìgbà, kódà nígbà tí wọ́n bá gbìyànjú láti ronúpìwàdà, kí wọ́n sì sún kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ náà.
2. Nígbàtí a bá n kábàmọ̀, tí à n jẹ̀bi, tí a sì n wà nínú ìtìjú. Èyí n sọ fún wa pé, ọ̀tá ti ní ibi gíga ní apá ibẹ̀yẹn.





## Dídá Àwọn Ibi Gíga Rẹ Mọ̀




Ṣe àkójọpọ̀ ayé rẹ fúnra rẹ. Èyà wo nínú ayé rẹ ni ó n mú ọ kùnà? Bí Jóṣúà àti Kálẹ́bù tí wọ́n ṣolóòótọ́, a ní láti ṣe amí ilẹ̀ náà. A ní láti mọ ibi tí àwọn ibi gíga

sàtánì wà. Àfojúsùn wa ni pé kí á wọ "ilẹ̀ ìlérí náà" ti ìlérí Ọlọ́run.

"Mósè sì rán wọn lọ ṣe amí ilẹ̀ Kénáánì, ó sì wí fún wọn pé, Ẹ gba ọ̀nà ìhà gúsù yìí, kí ẹ sì lọ sórí òkè ni. 18. Kí ẹ̀yin sì wo ilẹ̀ náà, bí ó ti rí; àti àwọn ènìyàn tí n gbé inú rẹ̀, bí wọ́n ṣe alágbára tàbí aláìlágbára, bí díẹ̀ ni wọ́n, tàbí púpọ̀; 19.Àti bí ilẹ̀ náà tí wọ́n n gbé ti rí, bí dídára ni, bí búburú ni, àti bí ilú ti wọn n gbé ti rí, bí nínú àgọ́ ni, tàbí nínú ìlú odi; 20. Àti bí ilẹ̀ náà ti rí, bí ẹlẹ́tù ni tàbí bí aṣálẹ̀, bí igi bá n bẹ nínú rẹ̀, tàbí kò sí. Kí ẹ̀yin kí ó sì mú ọkàn le, kí ẹ̀yin sì mú nínú èso ilẹ̀ náà wá. Njẹ́ ìgbà náà jẹ́ àkókò pípòn àkọ́so àjàrà. 21.Bẹ́ẹ̀ni wọ́n gòkè lọ, wọ́n sì ṣe amí ilẹ̀ náà láti ijù Sínì lọ dé Réhóbù, àti lọ sí Hámátì. 22. Wọ́n sì ti ìhà gúsù gòkè lọ, wọ́n sì dé Hébrónì, níbití Ahimani, Ṣeṣai, àti Talmai, àwọn ọmọ Anaki gbé





wà. (A ti tẹ Hebroni dó ní ọdún kéje ṣájú Soani ni Egipti.) 23. Wọ́n sì dé odò Eṣkolu, wọ́n sì rẹ́ ọwọ́ àjàrà kan, ti òun ti ìdì-èso àjàra kan láti ibẹ̀ wá, àwọn ènìyàn méjì sì fi ọ̀pá rù ú; wọ́n sì mú nínú èso-pomegranate, àti ti ọ̀pọ̀tọ́ wá. 24.Wọ́n sì sọ ibẹ̀ náà ní odò Eṣkolu, nítorí ìdì-èsò tí àwọn ọmọ Israẹli rẹ́ láti ibẹ̀ wá. 25.Wọ́n sì padà ní rírin ilẹ̀ náà wò lẹ́hìn ogójì ọjọ́. 26.Wọ́n sì lọ wọ́n to Mósè wá, àti Aarọni, àti gbogbo ìjọ àwọn ọmọ Israẹli, ní ijù Parani, ní Kadeṣi; wọ́n sì mú ọ̀rọ̀ padà tọ̀ wọ́n wá, àti gbogbo ìjọ, wọ́n sì fi èso ilẹ̀ náà hàn wọ́n. 27. Wọ́n sì rò fún u, wọ́n sì wípé, Àwá dé ilẹ̀ náà níbití ìwọ́ gbé rán wa lọ, nítòótọ́ ni ó n ṣàn fún wàrà àti fún oyin; èyí sì ni èso rẹ̀. 28. Ṣùgbọ́n alágbára ni àwọn ènìyàn tí n gbé inú ilẹ̀ náà, ìlú olódi sì ni ìlú wọn, wọ́n tóbi gidigidi: àti pẹ̀lúpẹ̀lú àwá

rí àwọn ọmọ Anaki níbẹ̀. 29.Àwọn ará Amaleki sì n gbé ilẹ̀ ìhà gúsù: àti àwọn Hitti, àti àwọn Jebusi, àti àwọn Amori, n gbé orí òkè: àwọn ara Kanaani sì n gbé ẹ̀bá òkun, àti ní agbègbè Jordani. 30. Kalebu sì pa àwọn ènìyàn lẹ́nu mọ́ níwájú Mose, ó sì wípé, Ẹ jẹ́ kí á gòkè lọ lẹ́ẹ̀kan, kí á sì gbà á; nítorípe àwá lè ṣe é. 31. Ṣùgbọ́n àwọn ọkùnrin tí ó bá a gòkè lọ wípé, Àwa kò lè gòkè tọ àwọn ènìyàn náà lọ; nítorí tí wọ́n lágbára jù wá lọ." Núméri 13:17-31

Ohun tí à n sọ níbí kìí ṣe ìgbàlà, bíkòṣe igbé ayé Krístẹ́nì aṣẹ́gun. Nínú àṣàyàn ẹ̀kọ́ ti afúrúgbìn.

“Ó sì fi òwe bá wọn sọ̀rọ̀ ohun púpọ̀, ó wípé, Wò ó, afúrúgbìn kan jáde lọ láti fúrúgbìn; 4.Bí ó sì ti n fún u, díẹ̀ bọ́ sí ẹ̀bá ọ̀nà, àwọn ẹyẹ sì wá, wọ́n sì ṣà á jẹ. 5.Díẹ̀ bọ́ sórí ilẹ̀ àpáta, níbití kò ní erùpẹ̀ púpọ̀, wọ́n





sì sọ jáde lọ́gán, nítorítí wọn kò ní ìjìnlẹ̀; 6. Nígbàtí òrun sì gòkè, wọ́n jóná: nítorí tí wọn kò ní gbòngbò, wọ́n sì gbẹ. 7. Díẹ̀ sì bọ́ sárin ẹ̀gún; nígbàtí ẹ̀gún sì dàgbà sókè, ó fún wọn pa. 8.Ṣùgbọ́n òmíràn bọ́ sí ilẹ̀ rere, ó sì so èso, òmíran ọgọ̀rọrún, òmíràn ọgọ́tọ̀ta, òmíràn ọgbọgbọ̀n. 9. Ẹnití ó bá ní etí, kí ó gbọ́. 10. Àwọn ọmọ-ẹ̀yìn rẹ̀ sì tọ̀ ọ́ wá, wọn bi í pé, Èṣe tí ìwọ fi n fi òwe bá wọn sọ̀rọ̀? 11. Ó sì dáhùn wí fún wọn pé, Ẹ̀yin ni a fi fún láti mọ ohun ìjìlẹ̀ ìjọba ọ̀run, ṣùgbọ́n àwọn ni a kò fi fún. 12. Nítorí ẹnikẹ́ni tí ó bá ni, òun ni a ó fi fún, òun ó sì ní ní ọ̀pọ̀lọpọ̀; ṣùgbọ́n ẹnikẹ́ni tí kò bá sì ni, lọ́wọ́ rẹ̀ ni a ó sì gba èyí náà tí ó ní. 13. Nítorínáà ni mo ṣe n fi òwe bá wọn sọ̀rọ̀; nítorí ní rírí, wọn kò rí, àti ní gbígbọ́, wọn kò gbọ́, bẹ́ẹ̀ni kò yé wọn. 14. Sí ara wọn ni ọ̀rọ̀ Isaiah woli sì ti ṣẹ, tí ó wípé, Ní

gbígbọ́, ẹ̀yin ó gbọ́, kì yíò sì ye yín, àti ní rírí ẹ̀yin o rí, ẹ̀yin kì yíò sì mòye. 15. Nítorítí àyà àwọn èniyàn wọ̀nyí sébọ́, etí wọn sì wúwo ọ̀ràn í gbọ́, ojú wọn ni wọ́n sì dì; nítorí kí wọ́n má ba fi ojú wọn ri, kí wọ́n kí ó má ba fi etí wọn gbọ́, kí wọn kí ó má ba fi àyà wọn mọ̀, kí wọ́n kí ó má ba yípadà, kí Èmi kí ó má ba mú wọn láradá. 16. Ṣùgbọ́n ìbùkún ni fún ojú yín, nítorí tí wọ́n rí, àti fún etí yín, nítorítí wọ́n gbọ́. 17. Lóòótọ́ ni mo sáà wí fun yín, ọ̀pọ̀lọpọ̀ wòlí àti olódodo ní n fẹ́ rí ohun tí ẹ̀yín rí, wọn kò sì rí wọn; wọ́n sì n fẹ́ gbọ́ ohun tí ẹ gbọ́, wọn kò sì gbọ́ wọn. 18. Nítorínáà ẹ gbọ́ òwe afúrúgbìn. 19. Nígbati ẹnìkan bá gbọ́ ọ̀rọ̀ ìjọba, tí kò bá sì yé e, nígbànáà ni ẹni búburú ni wá, a sì mú èyí tí a fún sí àyà rẹ kúrò. Èyí ni ẹnití ó gba irúgbìn lẹ́bà á ọ̀nà. 20. Ẹnití ó gba irúgbìn lórí àpáta, òun ni ó gbọ́ ọ̀rọ̀





náà, tí ó sì fi ayọ̀ gbà á kánkán. 21. Ṣùgbọ́n kò ní gbòngbò nínú ara rẹ̀, ó sì pẹ́ díẹ̀ ní àkókò kan, nígbàtí wàhálà àti inúnibíni sì dìdé nítorí ọ̀rọ̀ náà, lójúkannáà o kọsẹ̀. 22. Èyí pẹ̀lú tí ó gba irúgbìn sáàrin ẹ̀gún ni ẹnití ó gbọ́ ọ̀rọ̀ náà; àníyàn ayé yìí, àti ìtànjẹ ọ̀rọ̀ sì fún ọ̀rọ̀ náà pa, bẹ́ẹ̀ni ó sì jẹ́ aláìlésò. 23. Ṣùgbọ́n ẹnití ó gba irúgbìn sí ilẹ̀ rere ni ẹnití ó gbọ́ ọ̀rọ̀ náà, tí ó sì yé e; òun ni ó sì so èso pẹ̀lú, ó sì so òmíràn ọgọ́ rọrún, òmíràn ọgọ́tọ̀ta, òmíràn ọgbọngbọ̀n. 24. Òwe mìíràn ni ó pa fún wọn, wípé; Ìjọba ọ̀run dàbí ọkùnrin tí ó fún irúgbìn rere sí oko rẹ̀; 25. Ṣùgbọ́n nígbàtí èniyàn sùn, ọ̀tá rẹ̀ wá, ó fún èpò sínú àlìkámà, ó sì bá tirẹ̀ lọ. 26. Ṣùgbọ́n nígbàtí èhù rẹ̀ sọ jáde, tí ó sì so èso, nígbànáà ni èpò búburú fi ara hàn pẹ̀lú 27. Bẹ́ẹ̀ni àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ baálé náà tọ̀ ọ́ wá, wọ́n wí fún un pé, Olúwa,

> irúgbìn rere kí ìwọ fún sínú oko rẹ? Níbo ni ó ha ti ní èpò búburú? 28. Ó sì wí fún wọn pé, Ọ̀tá ni ó ṣe èyí. Àwọn ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ̀ sì bií pé, Ìwọ́ ha fẹ́ kí á lọ fà wọ́n tu kúrò?" Matt 13:3-28

A gbin irúgbìn náà sí oríṣi ilẹ̀, ní ìgbẹ̀yìn, ọ̀pọ̀ èso wá láti orí ilẹ̀ ọlọ́rà. Kílódé tí ilẹ̀ ọlọ́rà so èso? Nítorí pé gbogbo ohun tí ó n dí ìdàgbàsòkè lọ́wọ́ ni kò sí lórí ilẹ̀ ọlọ́rà. Nínú òwé náà, àwọn igbó, òkúta àti ẹ̀gún, pa irúgbìn náà (ọ̀rọ̀) tí afúrúgbìn sọ (Jésù). Jésù ṣe àlàyé àwọn igba náà bí àwọn làálàá ayé yìí àti ẹ̀tàn ọ̀rọ̀ púpọ̀.

> " Ṣùgbọ́n ẹnití ó gba irúgbìn sí ilẹ̀ rere ni ẹnití ó gbọ́ ọ̀rọ̀ náà, tí ó sì yé e; òun ni ó sì so èso pẹ̀lú, ó sì so òmíràn ọgọ́rọrún, òmíràn ọgọ́tọ̀ta, òmíràn ọgbọngbọ̀n" Matt 13:23

Gẹ́gẹ́bí Jóṣúà àti Kálẹ́bù ti ṣe, láti gba àkóso lórí ilẹ̀ wọn, a ní láti dá ibi tí àwọn ibi gíga wọ̀nyí wà mọ̀, kí á sì yọ wọ́n kúrò.





"Njẹ́ àwọn iṣẹ́ tíí ṣe ti ara farahàn, tí í ṣe ìwọ̀nyí: panṣágà, àgbèrè, ìwà-èérí, wọ̀bìà, 20. Ìbọ̀rìṣà, oṣó, ìríra, ìjà, ilara, ìbínú, asọ̀, ìṣọ̀tẹ̀, àdámọ̀. 21. Àrankàn, ìpanìyàn, ìmọtípara, ìréde-òrun, àti irú wọnnì: àwọn ohun tí mo n wí fun yín tẹ́lẹ̀ rí pé, àwọn tí n ṣe nkan báwọnnì, kì yíò jogún ìjọba Ọlọ́run" Gal 5:19-21

"Njẹ́ èyí ni mo n wí, tí mo sì n jẹ́rìí nínú Olúwa pé, láti ìsisìyí lọ kí ẹ̀yin kí ó máṣe rìn mọ́, àni gẹ́gẹ́ bí àwọn Kèfèrí ti n rìn nínú ìrònú asán wọn, 18.Òye àwọn ẹnití ó sòkùnkùn, àwọn tí ó sì di àjèjì sí ìwà-bí-Ọlọ́run nítorí àìmọ̀ tí n bẹ nínú wọn, nítorí líle ọkàn wọn:" Efésù 4:17-19

“Nítorínáà ẹ máa pa ẹ̀yà ara yín tí mbẹ ní ayé run: àgbèrè, ìwà-èérí, ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́, ìfẹ́ búburú, àti ojúkòkòrò, tí í ṣe ìbọ̀rìṣà: 6. Nítorí ohun tí ìbínú Ọlọ́run fi n bọ̀wá sórí àwọn ọmọ aláìgbọràn. 7. Nínú èyítí ẹ̀yin pẹ̀lú ti

n rìn nígbàkan rí, nígbati ẹ̀yin ti wà nínú nkan wọ̀nyí. 8.Ṣùgbọ́n nísisìyí, ẹ fi gbogbo wọ̀nyí sílẹ̀ pẹ̀lú: ìbínú, ìrúnú, àrankàn, ọ̀rọ̀-òdì, àti ọ̀rọ̀ ìtìjú kúrò ní ẹnu yín. 9.Ẹ má sì ṣe purọ́ fún ẹnìkejì yín, ẹ̀yin sá ti bọ́ ògbólógbòó ọkùnrin nì sílẹ̀ pẹ̀lú ìṣe rẹ̀; 10.Ẹ sì ti gbé ọkùnrin titun nì wọ̀, èyítí a sọdi titun sí ìmọ̀ gẹ́gẹ́bí àwòrán ẹnití ó dá a." Kol 3:5-10.

"Nítorí ẹ̀rù n bà mí pé, nígbàtí mo bá dé, èmi kì yíò ba yín gẹ́gẹ́ bí irú èyí tí mo fẹ́, àti pé èyin ó sì rí mi gẹ́gẹ́ bí irú èyí tí ẹ̀yin kò fẹ́: kí ìjà, owú-jíjẹ, ìbínú, ìpinyà, ìsọ̀rọ̀-ẹni-lẹ́yìn, ìjírọ̀sọ, fújà, ìrúkèrúdò, kí ó má ba wà." 2 Kor 12:20-21

Ní kété tí a bá ti ṣe ìdámọ̀ àwọn ibi gíga náà, a gbọ́dọ̀ dìde ogun sí wọn. Páùlù Àpóstélì nínú 2 Kor 10:5 fún wa ní ọ̀nà tí àwọn ibi gíga ti ẹ̀mí máa n gbà dìde. ó wípé ibi gíga ni àwọn àríyànjiyàn, ìdíbọ́n, èrò tí ó lòdì sí ìmọ̀ Ọlọ́run.





"Àwá n sọ gbogbo èrò kalẹ̀, àti gbogbo ohun gíga tí n gbé ara rẹ̀ ga sí ìmọ̀ Ọlọ́run, àwá sì n di gbogbo èrò ní ìgbèkùn wá sí ìtẹ́ríba fún Krístì;" 2 Kor 10:5

**Àríyànjiyàn:** Èyí kìí ṣe àríyànjiyàn pẹ̀lú àwọn ẹlòmíràn bíkòṣe ogun tí ó n ṣẹlẹ̀ nínú ọkàn ènìyàn nígbàtí ìparí èrò ọkàn ènìyàn àti èyí tí a fún wa nípa ìfihàn àtọ̀runwá bá tako ara wọn. Nínú irú ipò báyìí, láti gbàgbọ́ nínú èrò ọkàn ènìyàn jẹ́ kíkọ̀ ìfẹ́ Ọlọ́run tí a ti fihàn.

**Ìdíbọ́n:** Níbíyìí, ó n sọ nípa ìgbéraga nípa èyítí a gbé èrò ọkàn wa ga ju ìfihàn àtọ̀runwá lọ. O máa n fi ọgbọ́n orí dípò Ọlọ́run, ó sìn jẹ́ kí ènìyàn kí ó ní ìfọ̀kànbálẹ̀ nínú gbígbọ́kànlé ara ẹni ju gbígba ọ̀rọ̀ Ọlọ́run gbọ́ lọ. Èyí ni à n pè ní ìbọ̀rìṣà ọkàn.

**Èrò:** Èyí ni ìgbà tí a gbà sàtánì láàyé láti gbin èrò sínú ọkàn wa kí ó sì tàn wá láti rò wípé àwọn èrò wọ̀nyí jẹ́ èrò ọkàn wa.

Èṣù jẹ́ kí á gbèrò ọgbọ́n àti kápá àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó n ṣẹlẹ̀ nínú ìgbé ayé wa lòdì sí ìdarí ti Ọlọ́run fún gbígbé ayé wa.

Gbòngbò ibi gíga ni ìṣiyèméjì. Ibi gíga n mú kí á siyèméjì pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run kí á lè gbọ́kàn lé èrò ara wa.

Nítòótọ́, ibi gíga jẹ́ àwọn tí a gbọ́dọ̀ wò sàn kúrò nínú ọkàn wa, bí a bá fẹ́ gbé igbé ayé tí ó ní èso tí ó sì n so èso náà.

Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ kan láti inú iwé mímọ́, fún ìyéniyéké àti ìmòye síi lórí òtítọ́ yìí. Nínú Máttéu, orí kẹrin, bíbélì ṣe àlàyé ìtàn bí a ṣe dán Jésù Krístì wò lẹ́hìn ogójì ọjọ́ àti ogòjì òru tí ó ti n gbàwè.

> "Nígbàtí olùdanwò dé ọ̀dọ̀ rẹ̀, o ní, Bí ìwọ́ bá ṣe Ọmọ Ọlọ́run, pàṣẹ kí òkúta wọ̀nyí di àkàrà." Matt 4:3

Olùdanwò, èṣù, ni alágbára ọkùnrin tí í ṣe ìdánwò tí ó sì gbìyànjú láti tan Jésù. Nípa òtítọ́ ìfihàn Ọlọ́run, àti ìmòye Ẹ̀mí Mímọ́, mo ní láti jẹ́ kí o mọ̀ wípé èṣù kò farahàn nínú ara láti dán Jésù wò nínú





aginjù, ṣùgbọ́n nínú ẹ̀mí nípa ọfà ìjiyàn, idíbọ́n àti èrò tí ó lòdì sí ìfẹ́ Ọlọ́run tí ó n ta sínú ọkàn Jésù.

Bí Jésù Krístì bá ti ṣubú sínú àwọn ìdánwò wọnnì, òun ìbá ti fi ààyè fún ibi gíga láti dìde nínú ayé rẹ̀, nípa bẹ́ẹ̀ a sì ba iṣẹ́ ìránṣẹ́ àti ìpè ìránṣẹ́ rẹ̀ láyé jẹ́.

ORÍ KẸTA

# ALÁGBÁRA ỌKÙNRIN

Lẹ́yìn gbogbo ibi gíga, alágbára ọkùnrin wà. Lẹ́hìn iṣe, èrò àti ìfẹ́ inú tí kò sí ní ìbámu pẹ̀lú ọ̀rọ̀ àti òtítọ́ Ọlọ́run, ipá ti ẹ̀mí kan n bẹ lẹ́yìn rẹ̀.

Nígbàtí a dán Jésù wò nínú aginjù, ẹsẹ̀ ìkẹta, Máttéù orí kẹrin fi yé wa, ẹni tí alágbára ọkùnrin náà íṣe-Èṣù.

> “Nígbàtí olùdanwò dé ọ̀dọ̀ rẹ̀, o ní, Bí ìwọ́ bá ṣe Ọmọ Ọlọ́run, pàṣẹ kí òkúta wọ̀nyí di àkàrà." Matt 4:3

Èṣù jẹ́ ìdàkejì Ọlọ́run ní gbogbo ọ̀nà, gbogbo ohun tí Ọlọ́run yàn tí ó sì fẹ́ láti ṣe fún àwọn ọmọ rẹ̀ ní èṣù n fẹ́ láti ṣe ìdàkejì rẹ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé yíò kọ́kọ́ wá pẹ̀lú ẹ̀tàn láti fún ni ní ohun kan náà tí Ọlọ́run ti ṣèlérí.



Jésù Krístì wá láti fún ni ní ìyè àti ìyè ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ṣùgbọ́n èṣù wá láti pa àti láti pa ayé run. Jésù Krístì wá láti gbà sílẹ̀ àti láti tú sílẹ̀ nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ ìyè rẹ̀. Èṣù wá láti mú ní ìgbèkùn kí ó sì fi sínú ìdè nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ ẹ̀tàn rẹ̀. Ọlọ́run rán ọ̀rọ̀ rẹ jáde láti wò sàn àti láti gbà là.

Àwọn ọ̀rọ̀ ẹ̀tàn wọ̀nyí láti ọ̀dọ̀ èṣù tíí ṣe alágbára ọkùnrin ni ó fi ibi gíga lọ́lẹ̀ nínú ayé wa nígbàtí a bá ti subú sínú rẹ̀ nípasẹ̀ èrò wa, ìrònú wa àti àìgbàgbọ́ wa.

## Wíwó Ibi Gíga Palẹ̀ Àti Díde Alágbára Ọkùnrin

Ohun kan ṣoṣo ni a nílò láti wó ibi gíga gbogbo palẹ̀ àti láti pa alágbára ọkùnrin run nínú ayé wa, èyí tíí ṣe Ẹ̀mí Mímọ́.

O kò lè bá jà tàbí dìde ogun sí ẹnití o mọ̀ pé ó tóbi jù ọ́ lọ. Láìsí Ẹ̀mí Mímọ́ nínú wa, a jẹ́ aláìlágbára a kò sì lè kojú èṣù. Ọlọ́run mọ èyí, nítorínáà ni ó ṣe fún Jésù Krístì ní Ẹ̀mí Mímọ́ sáájú ìdánwò èṣù nínú aginjù.

"Nígbàtí a sì baptisi Jésù tán, ó jáde lẹ́sẹ̀kanná láti inú omi wá; sì wò ó, ọ̀rún ṣí sílẹ̀ fún u, ó sì rí Ẹ̀mí Ọlọ́run sọ̀kalẹ̀ bí àdàbà, ó sì bà lé e. Sì kíyèsí i, ohùn kan láti ọ̀run wá, wípé, Èyí ni àyànfẹ́ ọmọ mi, ẹnití ìnú mi dùn sí gidigidi." Matt 3:16-17

Nítorí pé ẹni tí ó ngbé inú Jésù Krístì ju èṣù lọ, òun kò le kojú rẹ̀ làti ba agbára rẹ̀ jẹ́.

"Èmi ni àjàrà, ẹ̀yin ni ẹka. Ẹnití ó n gbé inú mi, àti èmi nínú rẹ̀, òun ni yíò so èso ọ̀pọ̀lọpọ̀; nítorí ní yíyara yín kúrò lọ́ dọ̀ mi, ẹ kò lè ṣe ohun kan. 6.Bí ẹnikàn kò bá gbé inú mi,a gbé e sọnù gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ka, a sì gbẹ; wọn a sì kó wọn jọ, wọn a sì sọ wọ́n sínú iná, wọn a sì jóná. 7.Bí ẹ̀yín bá n gbé inú mi, tí ọ̀rọ̀ mi sì n gbe inú yín, ẹ ó bèrè ohunkóhun tí ẹ bá fẹ́, a ó sì ṣe é fun yín. 8.NÍnú èyí ni a yin Baba mi lógo pé, kí ẹ̀yin kí ó má a so èso púpọ̀; èyin ó sì jẹ́ ọmọ ẹ̀hìn mi. 9.Gẹ́gẹ́ bí Bàbá mi ti fẹ́ mi,





bẹ́ẹ̀ni èmí sì fẹ yín: ẹ dúró nínú ìfẹ́ mi." Jòhánù 15:5-9

Láìsí Ẹ̀mí Mímọ́ nínú ayé wa, a jẹ́ aláìní ìrànlọ́wọ́. A dán Jésù wò, a sì tàn án bí a ṣe n ṣe sí èmi àti ìrẹ. Ṣùgbọ́n òun kò ṣubú sínú rẹ̀ nítorí pé ó kún fún Ẹ̀mí Mímọ́. Òun kò rí èṣù nínú ara, bíkòṣe ní èrò. Èṣù ta ọfà ẹ̀tàn sí ọkàn rẹ̀ láti dẹ́rù bà á. ó sì mọ̀ lójú ẹsẹ̀ wípé àwọn ohun àti èrò wọnnì tí ó n lọ nínú ọkàn rẹ̀, kì í ṣe láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, ó sì dojú kọ̀ ọ́ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ pẹ̀lú òtítọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ̀run.

Bí èṣù bá ti farahàn nínú ara pẹ̀lú ìwà ìkà àti àìmọ́ rẹ̀ nì, bóyá Jésù ì bá ti nílò ìrànlọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ láti mọ̀ wípé ọ̀rọ̀ ẹnu èṣù kò ṣe é gbà. Sùgbọ́n nítorí pé èṣù wà nínú ẹ̀mí, òún nílò ìrànlọ́wọ́ ẹni tí ó mòye ipa ti ẹ̀mí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹni tí ó lè ṣe ìyàtọ̀ láàrin ohùn Ọlọ́run àti awọn ohun míràn nínú ẹ̀mí. À ní Ẹ̀mí Mímọ́

Ní ìgbà mélòó ni o ti ṣubú nígbà tí o bá ara rẹ ní ipò tí Jésù wà? Nígbàtí èrò láti pa irọ́, ja olè, ṣe àgbèrè, bú ni, yí ni pò àti

bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, bá wá sínú ọkàn rẹ̀ nípasẹ̀ ẹ̀tàn èṣù, njẹ́ ìwọ kò tẹríba?

Ọ̀rọ̀ tó tọ́ tí ó sì ṣe déédé wà nínú ìwé mímọ́ fún gbogbo ọfà ẹ̀tàn tí èṣù ti ta sínú ọkàn wa láti mú wa lẹ́rú àti láti gbé ibi gíga dìde nínú ayé wa. Ẹ̀mí Mímọ́ ni ó le sọ fún ọ àwọn ọ̀rọ̀ wọnnì tí ó yẹ ní àwọn irú ìgbà bẹ́ẹ̀, bí a bá kún fún un tí a sì tẹríba ní kíkún sí ìdarí rẹ̀.

Jésù kojú èsú pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ tí ó péye fún gbogbo ìkojú rẹ̀.

> "Ṣùgbọ́n ó dáhùn wípé, A ti kọ̀wé rẹ̀ pé, Ènìyàn kì yíò wà láàyè nípa àkàrà nìkan, bíkòṣe nípa gbogbo ọ̀rọ̀ tí ó ti ẹnu Ọlọ́run jáde wá." Matt 4:4

> Jésù sì wí fún u pé, A tún kọ ọ́ pé, Ìwọ kò gbọdọ̀ dán Olúwa Ọlọ́run rẹ wò." Matt 4:7

## Pípa Alágbára Okùnrin Náà Run

Láti pa ibi gíga náà run pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run kò tó, bí kò ṣe pé kí á pa alágbára





ọkùnrin tí ó wà lẹ́hìn àwọn ibi gíga wọ̀nni run kí á ba lè di òmìnira nítòótọ́.

Jésù mọ èyí nígbatí ó di ẹlẹ́ẹ̀kẹta tí èṣù wá dan wò, tí ó báwí, tí ó sì lé alágbára ọkùnrin náà jáde. Jésù wípé, padà lẹ́yìn mi, sàtánì, nítorí tí a ti kọ ọ́ wípé, ìwọ yíò sin Olúwa Ọlọ́run rẹ, òun nìkan ni ìwọ ó sì sìn.

> "Nígbànáà ni Jésù wí fún u pe, Padà kúrò lẹ́yìn mi, Sàtánì: nítorí a kọ̀wé rẹ pé, Olúwa Ọlọ́run rẹ ni kí ìwọ kí ó foríbalẹ̀ fún, òun nìkanṣoṣo ni kí ìwọ máa sìn." Matt 4:10

> "Nígbànáà ni Èṣù fi í sílẹ̀ lọ; sì kíyèsí i, àwọn angẹ́lì tọ̀ ọ́ wá, wọ́n sì n ṣe ìránṣẹ́ fún u." Matt 4:11

Àfi ìgbà tí Jésù de alágbára ọkùnrin náà, òun kò sí ní ìsinmi àti pé àwọn ángẹ́lì kò sì wá ṣe ìránṣẹ́ fún un.

Nígbàtí ọkàn rẹ bá kún fún èrò tí ó n gbé ara rẹ̀ ga ju ìmọ̀ Ọlọ́run lọ. Nígbàtí èrò àti parọ́, dá ẹ̀ṣẹ̀ àti ṣe ohunkóhun

lòdì sí Ọlọ́run bá nwá sínú ọkàn rẹ, njẹ́ ò n kọ ojú ìjà sí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run kí o sì wó irú èrò bẹ́ẹ̀ palẹ̀ tàbí ó n tẹ̀síwájú láti máa fi ààyè gba irú èrò bẹ́ẹ̀ nínú ọkàn rẹ títí yíò fi mú ọ lẹ́rú tí yíò sì dá ibi gíga sílẹ̀?

Bí o bá kọjú ìjà sí àwọn èrò bẹ́ẹ̀ àti ẹ̀tàn láti ọ̀dọ̀ èṣù, tí o sì n padà wá ní ìgbà dé ìgbà, bóyá o kò tíì ṣẹ́gun alágbára ọkùnrin tí ó wà lẹ́hìn ibi gíga náà ni.

Nígbàti o bá ṣe èyí, ìwọ yíò di òmìnira lọ́wọ́ ẹ̀tàn èṣù, àwọn áńgẹ́lì yíò sì wá ṣe ìránṣe fún ọ fún irú ìṣẹ́gun bẹ́ẹ̀. O ní láti fi ara sílẹ̀ kí o sì gbọ́kànlé ìrànlọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ ní pátápátá.

Ẹ̀mí Mímọ́ n ràn wá lọ́wọ́ ní àwọn ọ̀nà wọ̀nyí nígbàtí a bá gbọ́kànlé e ní kíkún tí a sì fi ara wa sílẹ̀ fún ìdarí rẹ̀.

a. Ẹ̀mí Mímọ́ n fi hàn wá, àwọn ohun tí ojú ara wa kò lè rí, ohun tí irinṣẹ́ atọ́nà n ṣe fún jagunjagun, ni Ẹ̀mí Mímọ́ n ṣe fún onígbàgbọ́. Ẹ̀mí Mímọ́ yíò fi ìmọ̀yàtọ̀, ìfihàn fún ni ju ojú àti òye ti ara lọ.





b. Ẹ̀mí Mímọ́ n so wá pọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí a rán tí a sì fi hàn fún ìtúsílẹ̀ wa.

"Ó rán ọ̀rọ̀ rẹ̀, ó sì mú wọn lára dá, ó sì gbà wọ́n kúrò nínú ìparun wọn." Orin Dáfídì 107:20

"Wò ó! Bí ọ̀rọ̀ òtítọ́ ti lágbára tó Ṣùgbọ́n kínni àròyé ìbáwí yín jásí?" Jóbù 6:25

d. Ẹ̀mí Mímọ́ n fi agbára fún wa nínú ẹ̀mí. Òun ni ó n fún ẹ̀mí wa ní agbára.

**Báwo ni a ṣe n fi Ẹ̀mí Mímọ́ wó ibi gíga palẹ̀ àti láti pa ọkùnrin alágbára náà run?**

1. O gbọ́dọ̀ ronúpìwàdà kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Bí a bá rí àìṣòdodo àti àìṣedédé nínú wa, a gbọ́dọ̀ ronúpìwàdà kúrò nínú rẹ̀, kí á má ba fún èṣù ní àyè tàbí agbára lórí ayé wa.

"Bí èmí bá gba ẹ̀ṣẹ̀ ní àyà mi, Olúwa kì yíò gbóhùn mi:" Orin Dáfídì 66:18

"Àwá sì ti múra tán láti gbẹ̀san gbogbo àìgbọ́ràn, nígbàtí ìgbọràn yín bá pé." 2 Kor 10:6.

2. Ṣe àwári ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí ó kan ibi gíga yi. Nígbàtí a n dán Jésù wò nínú aginjù, o kojú gbogbo ìdojúkọ èṣù nípa lílo àwọn òtítọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run láti inú ìwé mímọ́. O gbọ́dọ̀ wá inú ìwé mímọ́ lọ́sàn àti lóru, kí ò sì ṣe àwárí àwọn ọ̀rọ̀ tí o nílò fún gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀. Gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó n ṣẹlẹ̀ ni ọ̀rọ̀ tí ó yè koro wà fún, ṣe àwárí rẹ̀ kí o sí lò ó.

3. Ṣe àṣàrò lórí ọ̀rọ̀ tí o ti rí ni, nígbàti o bá ti ṣe àwárí ọ̀rọ̀ tí o nílò nínú ìwé mímọ́, níṣe ni ó dàbí wípé kí a rí àpótí tí ó kún fún ìṣura. Bí o kò bá tí ì ṣe àṣàrò lórí ọ̀rọ̀ náà tí o ti wárí, o kò tíì ṣí àpọ́tí ìṣura náà láti mọ irú ìṣura tí ó wà nínú rẹ̀. Ìṣura tí ó ṣá wà nínú àpótí náà ni o nílò, kí ì ṣe àpótí fúnra rẹ̀, ṣe àṣàrò lórí ọ̀rọ̀ tí o ti wá rí, kí o ba lè rí ìṣura tí ó pamọ́ sínú rẹ̀ àti láti mú wọn dání ní ọwọ́ rẹ.

"Ṣùgbọ́n dídùn inú rẹ̀ wà ní òfin Olúwa; àti nínú òfin rẹ̀ ni ó n ṣe àṣàrò ní ọ̀sán àti ní òru." Orin Dáfídì 1:2





"Ojú mi là sílẹ̀ kedere ní ìṣọ́-òru, kí èmi kí ó lè ma ṣe àṣàrò nínú ọ̀rọ̀ rẹ." Orin Dáfídì 119:148

"Là mí ní ojú, kí èmi kí ó lè ma wo ohun ìyanu wọ̀nnì láti inú òfin rẹ." Orin Dáfídì 119:18

4. Lo ìfàmìòróróyàn ti Ẹ̀mí Mímọ́

"Ohun náà ni àwá sì n sọ, kìí ṣe nínú ọ̀rọ̀ tí ọgbọ́n ènìyàn n kọ́ni, ṣùgbọ́n èyítí Ẹ̀mí Mímọ́ fi n kọ́ni, èyítí à n fi ohun Ẹ̀mí wé ohun Ẹ̀mí. 14. Ṣùgbọ́n ènìyàn nípa ti ara kò gba ohun ti Ẹ̀mí Ọlọ́run wọ̀nnì: nítorípé wèrè ni wọ́n já sí fún u: òun kò sì lè mọ̀ wọ́n, nítorí nípa ti Ẹ̀mí ni a fi n wádì í wọn." 1 Kor 2:13-14

Gba Ẹ̀mí Ọlọ́run láàyè láti darí rẹ bí o ti n kojú àwọn ogun náà.

"Yíò sì ṣe ní ọjọ́ náà, ni a ó gbé ẹrù rẹ̀ kúrò ní èjìká rẹ, àti àjàgà rẹ̀ kúrò ní ọrùn rẹ, a ó sì ba àjàgà náà jẹ́ nítorí ọ̀rá púpọ̀." Isaiah 10:27

Nígbàtí o bá lo ìfàmìòróróyàn ti Ẹ̀mí Mímọ́, nígbànáà ni ìṣẹ́gun yíò tó ọ lọ́wọ́. Ẹ̀mí Mímọ́ kò le kùnà. Ìfàmìòróróyàn tí a gbà lọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ kìí ṣe fún títo ilé. Wọ́n wà fún ìjàkadì ti ẹ̀mí. Bí àwọn ìfàmìòróróyàn wọ̀nyí ṣe pọ̀ tó lórí ayé wa, ní í ṣe pẹ̀lú bí a ti n lo àwọn èyí tí ó wà nínú ayé wa lónìí.

5. Pa ọkùnrin alágbára náà àti ibi gíga wọn run nípa gbígbàdúrà nínú ẹ̀mí.

"Nítorí ohun ìjà wa kìí ṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó ní agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀; Àwá n sọ gbogbo èrò kalẹ̀, àti gbogbo ohun gíga tí n gbé ara rẹ̀ ga sí ìmọ̀ Ọlọ́ run, àwá sì n di gbogbo èrò ní ìgbèkùn wá sí ìtẹ́ríba fún Krístì;" 2Kor 10:4-5

“Pẹ̀lú gbogbo àdúrà àti ẹ̀bẹ̀ ni kí ẹ máa gbàdúrà nígbàgbogbo nínú Ẹ̀mí, kí ẹ sì ma ṣọ́ra sí i nínú ìdúró-ṣinṣin gbogbo, àti ẹ̀bẹ̀ fún gbogbo ènìyàn mímọ́;" Eféṣù 6:18





Ọ̀kan nínú àwọn ohun ìjà tí ó tóbi jù fún onígbàgbọ́ láti lò nínú ìjàkadì ti ẹ̀mí ni gbígbàdúrà pẹ̀lú ìfèdèfọ̀ tàbí nínú ẹ̀mí.

"Nítorí ẹni tí n sọ̀rọ̀ nínú èdè àìmọ̀, kò bá ènìyàn sọ̀rọ̀ bíkòṣe Ọlọ́run: nítorí kò sí ẹnití ó gbọ́; ṣùgbọ́n nípa ti Ẹ̀mí ó n sọ ohun ìjìnlẹ̀:" 1Kor 14:2

Ní kété tí a bá ti yẹ ara wa wò wípé kò sí àìṣedédé tàbí ẹ̀ṣẹ̀ nínú wa, tí a bá sì ti ronúpìwàdà lótìítọ́ kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ àti ìkùnà wá ní ọ̀nàkọnà, ní kété tí Ọlọ́run bá sì ti n gbé inú wa, tí à n ṣe àṣàrò nínú ọrọ Rẹ̀ lójojúmọ́, kò sí ojú òkùnkùn, kò sí ibi gíga tàbí ọkùnrin alágbára tí ó lè gbórí dúró lábẹ́ agbára tí à n mú jáde nígbàtí a bá n gbàdúrà nínú ẹ̀mí. Èyí ni ọ̀nà tí ó dájú fún ìṣẹ́gun wa ní wíwó ibi gíga palẹ̀ àti pípa ọkùnrin alágbára gbogbo run.

Ṣùgbọ́n bí a ti sàlàyé lákọ̀kọ́, a gbọ́dọ̀ ṣe ohun àkọ́kọ́ ní àkókò, kí á má ba dàbí ẹni tí n lú afẹ́fẹ́.

Kínni ìdí ti mo fi gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ bá ibi gíga wí nínú ìjà ẹ̀mí?

Nínú gbogbo ogun àti ìjàkadì ti ẹ̀mí, ogun tí ó lágbára jù láti jà ni ogun ti inú tàbí ogun ẹran ara. Bí o bá le borí ara rẹ àti àwọn ohun tí ó n bá Ọlọ́run jìjàgbara nínú ayé rẹ, nígbànáà ni ìṣẹ́gun rẹ dájú lórí àwọn ìyókù.

O ní láti mòye wípé bíbá àwọn agbára òkùnkùn jà, àwọn ẹ̀mí èṣù, àwọn àjẹ́ àti oṣó, jẹ́ ohun tí kò ṣòro rárá, nitorí tí a ti fún ọ ní àṣẹ lórí wọn, àṣẹ yìí sì dájú nígbagbogbo àti ní ọjọ gbogbo, ṣùgbọ́n, àwọn ohun kan wà tí ó lè fi ọ́ sí ibi ìṣàkósò àṣẹ náà lórí àwọn agbára òkùnkùn wọ̀nyí.

Bí o bá lè borí ẹ̀ran ara rẹ, iyèméjì rẹ, ìfẹ́kúfẹ̀ rẹ, àìgbàgbọ́ rẹ, irọ́ pípa rẹ, ìbọ́rìṣà rẹ, àgàbàgebè rẹ àti ìgbéraga rẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ; àwọn ohun tí í ṣe ibi gíga tí ó n dí ọ lọ́wọ́ láti rìn ní ibi ìṣàkóso ògo, ore-ọ̀fẹ́ àti àṣẹ tí Ọlọ́run ti yàn fún ọ láti rìn, láti ìgbà tí o ti di ọmọ rẹ̀, nígbànáà, o ti di ẹni tí a kò lè dá dúró fún agbára òkùnkùn Kankan.






Yíò yà ọ́ lẹ́nu, bí ìwọ yíò ti ṣe máa gbádùn ìṣẹ́gun ojojúmọ́ lórí ìjàkadì ti ẹ̀mí gbogbo.

ORÍ KẸRIN

# ỌGBỌ́N ÀTI JA ÌJÀ TI Ẹ̀MÍ

Bí a fẹ́, bí a sì kọ̀, ààrin ogun ni a wà. Ní gbogbo àyíká wa ni ogun wà, tí ó sì n ṣẹlẹ̀ nínú ẹ̀mí, ní inú àti ní òde.








Nípasẹ̀ ẹ̀mí, a le mọ nípa ogun yìí, kí á sì mọ̀ bí a ti n gbé nínú ìṣẹ́gun, láìsí ìdójútì. Mímòye àti ja ogun, àti bí a ti gbọ́ dọ̀ wọ̀yá ìjà pẹ̀lú ọ̀tá ṣe pàtàkì bí a bá fẹ́ ìṣẹ́gun. Bí àpẹẹrẹ, bí o bá jẹ́ ajagun tí ò n gbìyànjú láti wọ̀yá ìjà pẹ̀lú ọ̀tá kan àti láti fi òpin sí ogun gbígbé rẹ̀, ṣùgbọ́n tí o kò tilẹ̀ mọ ibi tí ìdojúkọ náà tí n bọ̀wá, ọkàn rẹ ki yíò balẹ̀, ìwọ yíò sì ma lérò bóyá àwọn ọmọ ogun rẹ̀ yíò ní agbára tí ó tó láti kojú ìdojúkọ nígbàtí ó bá dé. Ní ọ̀nà míràn, bí àwọn ajagun rẹ bá ní ìmòye nípa ọ̀tá, o lè ṣe ètò ìmúrasílẹ̀ fún ìdojúkọ ọ̀tá.

Bíbélì nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ gbà wá láàyè láti rí ọ̀tá wa àti láti mọ̀ nípa ogun ẹ̀mí náà. Láìsí ìwé mímọ́, a ó kàn ma bá ọ̀tá tí a kò rí, tí a kò sì mọ̀ jà ni, láì tilẹ̀ mọ̀ wípé a wà ní ojú ogun. Bíbélì fi hàn nípasẹ̀ ẹ̀mí Ọlọ́run, ayé àìrí tí ó yí wa ká. Nínú ayé ẹ̀mí yìí, a ní ọ̀tá kan tí ó wà ní ìwàyá ìjà pẹ̀lú wa ní gbogbo ìgbà, tí ó sì fẹ́ dá ìjọba Ọlọ́run dúró láti gbèrú sí i. Sátánì àti àwọn angẹ́lì rẹ̀ tí ó ṣubú ni ọ̀tá náà! Wọ́n

n wa láti pa wá run kí wọ́n mú wa jẹ́ àláìlágbára sí iṣẹ́ wọn. Ogun wà tí ò n jà ní àyíká wa, àwọn ohun èlò Sàtánì sì n ṣiṣẹ́ kárakára nínú ogun yìí.

Sàtánì n lo ọkùnrin àtijọ́ wá (ẹran ara) àti ẹ̀dá ìṣubú wa láti bá wa jagun nínú ẹ̀mí, ṣùgbọ́n gbígbé Ẹ̀mí Mímọ́ nínú wa, nmú wa gbáradì fún ogun ẹ̀mí tí ó wà níwájú. Nípasẹ̀ ìwé mímọ́ àti ìdánilójú, Ẹ̀mí Ọlọ́run n gbé wa ní ara dì fún ogun. Páùlù nínú ìwé Efésù orí kẹfà ṣe àtúpalẹ̀ ohun ìjà ajagun ti ẹ̀mí.

> "Ẹ gbé gbogbo ìhámọ́ra Ọlọ́run wọ̀n, kí ẹ̀yin kí ó le kọ ojú ìjà sí arékérekè Èṣù. 12. Nítorípé kìí ṣe ẹ̀jẹ̀ àti ẹran-ara ni àwá n bá jìjàkadì, ṣùgbọ́n àwọn ìjòyè, àwọn ọlọ́lá, àwọn aláṣẹ ibi òkùnkùn ayé yìí, àti àwọn ẹ̀mí búburú ní ojú ọ̀run. 13.Nítòrínáà ẹ gbé gbogbo ìhámọ́ra Ọlọ́run wọ̀ kí ẹ̀yin kí ó lè dúró tiri sí ọjọ́ ibi, nígbàtí ẹ̀yín bá sì ti ṣe ohun gbogbo tán, kí ẹ sì dúró. 14. Ẹ dúró nítorínáà lẹ́yìn tí ẹ ti fi àmùrè òtítọ́ di ẹ̀gbẹ́ yín, tí ẹ sì ti di ìgbáìyà òdodo nì mọ́ra; 15. Tí ẹ sì ti fi ìmúra ìhìnrere àlàáfíà wọ ẹsẹ̀ yín ní bàtà; 16.Lékè gbogbo rẹ̀, ẹ mú apata ìgbàgbọ́, nípa èyítí ẹ̀yin ó le ma fi paná gbogbo ọfà iná ẹni ibi nì. 17. Kí ẹ sì mú àṣíborí ìgbàlà, àti idà Ẹ̀mí, tí í ṣe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run: 18. Pẹ̀lú gbogbo àdúrà àti ẹ̀bẹ̀ ni kí ẹ máa gbàdúrà, nígbàgbogbo nínú Ẹ̀mí, kí ẹ sì máa ṣọ́ra sí I nínú ìdúroṣinṣin gbogbo, àti ẹ̀bẹ̀ fún gbogbo ènìyàn mímọ." Efésù 6:11-18





Nítorí náà, gẹ́gẹ́ bí ajagun ti ẹ̀mí a ní láti mọ̀ wípé ojú ogun ni a wà, nígbàtí a sì ti wà ní ojú ogun, a ní láti ṣe àkójọpọ̀ ọgbọ́n àti ọ̀nà láti ja ogun tiwa, kí á ba lè gbé ìgbé ayé aṣẹ́gun àti pẹ̀lú kí á mú ìjọba Ọlọ́run gbòòrò si.

## Gbígbáradì fún Ogun

Báwo ni a ṣe n gbé àwọn ogun yìí sí wa? Bí a ó ti ri, à n gbé àwọn ogun wọ̀nyí nínú ọkàn ènìyàn, nípasẹ̀ ẹni tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ti n

ṣẹlẹ̀ nínú ara n ṣe iṣẹ́. Àwa jẹ́ ẹni ẹ̀mí nínú ẹran ara; àwọn ogun wọ̀nyí tí à n gbé sí wa jẹ́ nínú ojú ìjà ti ọkàn. Sàtánì n darí ogun kan nínú ẹ̀mí, ó n bá ọkàn wa jagun.

“Nínú àwọn ẹnití ọlọ́run ayé yìí ti sọ ọkàn àwọn tí kó gbàgbọ́ di afọ́jú, kí ìmọ́lẹ̀ ìhìnrere Krístì tí ó lógo, ẹnití í ṣe àwòrán Ọlọ́run, kí ó máṣe mọ́lẹ̀ nínú wọn." 2 Kor 4:4

Níbí yìí, a pe sàtánì ní "ọlọ́run ayé yìí", ẹni tí ó n fọ́ ojú àwọn ẹni tí ó ti sọnù kí wọ́n má ba le rí ìhìnrere. Ọkàn ènìyàn ni ibùdó ìjà sàtánì, sàtánì kò ja ogun ara, bíkòṣe ti ẹ̀mí, ó n dojú ìjà kọ ọkàn àti ẹ̀mí ènìyàn. Sàtánì àti àwọn angẹ́lí rẹ̀ tí ó subú n gbé àwọn ohun wọ̀nyí ṣe nínú ẹ̀mí, nípa irọ́ àti ẹ̀tàn, tí wọ́n sì n pàrọwà àìpé ẹ̀dá ènìyàn.

Nígbàtí a bá tọ Krístì wá, ọkàn àti ìrònú wa yíò di yíyípadà nípasẹ̀ agbára Ẹ̀mí Mímọ́ tí n gbé nínú wa. Àwa náà ẹ̀wẹ̀, gbọ́dọ̀ kó ipa níbi tí a ti le jọ̀wọ́ ẹran





ara wa fún Ẹ̀mí Ọ̀lọ́run, tàbí kí á kọ̀ láti ṣe bẹ́ẹ̀. Bí a bá jọ̀wọ́ ẹran ara wa fún ẹ̀mí, a ó kún fún ẹ̀mí, bí Olúwa yíò ti gba ayé wa tí yíò sì mọ ọ́ sí àwòrán Krístì. Bí a bá ti ṣe jọ̀wọ́ ara wa sí, ní a ó ṣe dàbí Krístì sí. Nítorí ìdí èyí nínú ìwé Romu orí kejìlá, a kà nípa ìlò wa láti jẹ́ ẹbọ ààyè tí í kọ àfẹ́rí ẹ̀dá àtijọ́ wa sílẹ̀, tí ì sì í paradà láti di titun nínú ọkàn wa." Ẹ̀dá àtijọ́ ní ọ̀nà ìṣubú tí òun fi n ronú, èyítí ó fi ààyè gba ẹ̀tàn Sàtánì.

> "Nítorínáà mo fi ìyọ́nú Ọlọ́run bẹ̀ yín, ará, kí ẹ̀yin kí ó fi ara yín fún Ọlọ́run ní ẹbọ ààyè, mímọ́, ìtẹ́wọ́ gbà, èyí ni iṣẹ́-ìsìn yín tí ó tọ̀nà. 2.Kí ẹ má sì da ara yín pọ̀ mọ́ ayé yìí, ṣùgbọ́n kí ẹ paradà láti di titun ní ìrò-inú yín, kí ẹ̀yin kí ó lè rí ìdí ìfẹ́ Ọlọ́run, tí ó dára, tí ó sì ṣe ìtẹ́wọ́gbà, tí ó sì pé." Rom 12:1-2.

A ní láti mọ̀ wípé ogun náà kìí ṣe tiwa, bíkòṣe ti Ẹ̀mí Mímọ́ tí ó n gbé inú wa. Òhun tí ó nira jù fún ọ̀pọ̀ onígbàgbọ́ ni kí á má ṣe dù mọ́ ẹ̀mí lọ́wọ́. A kọ̀ láti fi àkóso

ara wa sílẹ̀ nípa bẹ́ẹ̀ a n wà ní ààrin ìjàgbara fún àkóso ní ìgbàgbogbo. Kí ogunkógun tó lè di gbígbé, a ní láti mọ ibi tí ogun náà ti wá. Níbo ni ọ̀tá ti n dojúkọ wá?

Ní àkọ́kọ́, a ní láti mòye wípé ogun náà jẹ́ láti inú wá. Ohún tí a bá ṣe pẹ̀lú àwọn àmọ̀ràn wọ̀nyí ní inú ọkàn wa ni ó n mú wa ṣẹ̀. Àwọn ohun tí a gbà láti yàn ni. Ìdojúkọ náà jẹ́ nípasẹ̀ àìpé ẹ̀dá ènìyàn àti àwọn ìdánwò tí ó yí wa ká kiri. Ní èkejì, a ní agbára láti yàn, àwa kìí ṣe aláìlágbára nínú ìjàkadì yí.

Àwọn ìgbésẹ̀ mẹ́rin kan wà láti ní ìṣẹ́gun lórí ẹ̀dá àtijọ́ wa kí á sì ṣètò ọ̀nà àtija ogun.

1. A ní láti jọ̀wọ́ ẹran ara wa fún ẹ̀mí.
2. Mọ̀ dájú ibi tí ìdánwò ti n wá.
3. Dá gbòngbò ẹ̀ṣẹ̀ mọ̀.
4. Mo èyí tí í ṣe gbòngbò náà gan.





1. **A ní láti jọ̀wọ́ ẹran ara wa fún ẹ̀mí**

Ohun àkọ́kọ́ ni pé kí á jọ̀wọ́ ara wa fún Olúwa. Njẹ́ a ṣetán láti fi àwọn ẹ̀yà ayé wa sílẹ̀? Romu orí kejìlá tọ́ka sí ara wa gẹ́gẹ́ bí "ẹbọ ààyè", kíni ìtukọ̀ èyí? Ní ìgbà ọjọ́ àwọn àlùfá Júù, à n fi alààyè ẹranko rúbọ; wọ́n fi ẹ̀mí àwọn ẹranko wọ̀nyí ṣe ìbẹ̀bẹ̀ fún ẹ̀ṣẹ̀ àwọn ẹlòmíràn. Ní ọ̀nà kannáà tí wọ́n ti fi ẹ̀mí wọn sílẹ̀, a gbọ́dọ̀ fi ìgbé ayé wa àtẹ̀hìnwá sílẹ̀, a sì gbọ́dọ̀ ṣetán láti fi ẹ̀dá wa àtijọ́ rúbọ. Nípa bẹ́ẹ̀, a ó di "ẹbọ ààyè".

Bí àpẹẹrẹ, lẹ́yìn ìgbà tí o ti tọ Krístì wá, àwọn ọ̀rẹ́ rẹ pè ọ́ sí ilé ọtí, tí ó ni ju kìkìdá ọ̀tí àti ohun ìpanu lọ. O fura bí ẹ̀mí tí n gbé nínú rẹ nípa lílọ sí irú ibi báyìí. O tún wá gbọ́ ohùn láti inú tí n sọ wípé, bí o kò bá lọ, wọn ó pa ọ́ ti nínú ọ̀rẹ́ ṣíṣe yín. Kíni ìwọ́ ṣe lẹ́yìn èyí? Njẹ́ ìwọ́ fi ẹ̀yà ayé rẹ yìí rúbọ bí?

Àwọn àpẹẹrẹ díẹ̀ ni èyí, fún ohun tí ó túmọ̀ sí láti jẹ́ "ẹbọ ààyè", ó gbọ́dọ̀ jẹ́ ìfẹ́ inú rẹ láti jọ̀wọ́ ìṣàkóso ayé rẹ fún Ẹ̀mí Mímọ́.

2. **Mọ̀ dájú, ibi tí ìdánwò ti n wá**

Ní kété tí a bá ti gbé ìgbésẹ̀ láti jọ̀wọ́ ayé wa, a wá nílò láti mọ̀ dájú, ibi tí orísun ìdánwo wa ti n wá. Kíni orísun ìdánwò wa?

Bíbélì fi yéni yéké, Sátánì jẹ́ kìnìún tí n bú ramúramù tí ó n wa ẹni tí òun yíò pajẹ.

"Ẹ máa wà ní àìrékọjá, ẹ máa ṣọ́ra; nítorí Èṣù, ọ̀tá yín, bí kìnìún tí n ké ramúramù, n rìn kákiri, ó n wá ẹnití yíò pajẹ kiri: 9.Ẹnití kí ẹ̀yin kí ó kọjú ìjà sí pẹ̀lú ìdúroṣinṣin nínú ìgbàgbọ́, kí ẹ̀yin kí ó mọ̀ pe ìyà kannáà ni àwọn ará yín tí n be nínú ayé njẹ." 1 Pet 5:8-9

Níṣe ni à n yàn nígbàtí a bá n dán wa wò, nígbàtí a bá n fi ara wa sílẹ̀ fún ìdánwò wa, òun a sì fà wá lọ sínú ẹ̀ṣẹ̀, nígbàtí ohun àfẹ́rí bá borí ẹ̀dá wa titun. Èyí má n darí sí ikú, nípa ti ara àti ti ẹ̀mí bí a kò bá mójú to.





"Ṣùgbọ́n olúkúlùkù ni à n dánwò, nígbàtí a bá ti ọwọ́ ìfẹ́kúfẹ̀ ara rẹ̀ fà á lọ tí a sì tàn án jẹ. 15.Njẹ́, ìfẹ́kúfẹ̀ náà nígbàtí ó bá lóyún, a bí ẹ̀ṣẹ̀, àti ẹ̀ṣẹ̀ náà nígbàtí ó bá sì dàgbà tán, a bí ikú."Jákọ́bù 1:14-15

Àwọn ohun tí ó yí ọ ká, nsa ipá púpọ̀ nínú ẹṣe rẹ, àwọn nkan bíi;

- Ìrò inú rẹ, àfẹ́rí rẹ, àti èrò rẹ.
- Àwọn èniyàn tí ó yí ọ ká.
- Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àti àwọn ohun tí ó yí ọ ká.
- Sàtánì.

Ọlọ́run ni Tirẹ̀ máa n dín ìdánwò kù; àwọn ìdánwò wọ̀nyí nìkan ni òmìnira tí Sàtánì ní. Ọlọ́run máa n gba Sàtánì láyè láti dán wa wò, nítorí nípasẹ̀ àwọn ìdánwò wọ̀nyí ni à n dán ìgbàgbọ́ wa wò. Nínú ìwé Jóbù, a rí Sàtánì ní ibi iṣẹ́ rẹ̀, òún sọ nípa Jóbù wípé a fi odi yí I ká.

"Ìwọ kò ha ti ṣọgbà yí i ká, àti yí ilé rẹ̀ àti yí ohun tí ó ní ká ní ìhà gbogbo? Ìwọ́ bù sí iṣẹ́ ọ́wọ́ rẹ̀, ohun ọ̀ṣìn rẹ̀ sì n pọ̀ síi ní

ilẹ̀." Jobu 1:10 èyí tí kò gba òun láàyè láti da kọjá. Èyí náà níí ṣe pẹ̀lú wa. Ọlọ́run ti ṣe ọ̀nà àbáyọ kúrò nínú ìdánwò gbogbo, níṣe ni a kàn gba Sàtánì láàyè láti ṣe díẹ̀. Ní pàtàkì jùlọ, Ọlọ́run fi ààyè gba ìdánwò, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé Ọlọ́run kìí dán ẹnikẹ́ni wò.

> "Kò sí ìdánwò kan tí ó tí i ba yín, bíkòṣe irú èyítí ó mọ níwọ̀n fún ènìyàn: ṣùgbọ́n olódodo ni Ọlọ́run, ẹnití kì yíò jẹ́ kí á dan yín wò ju bí ẹ̀yín ti le gbà; ṣùgbọ́n tí yíò ṣe ọ̀nà àtiyọ pẹ̀lú nínú ìdánwò náà, kí ẹ̀yin kí ó ba le gbà á." 1 Kor 10:13.

Rántí wípé Sàtánì dán Jésù pàápàá wò, pẹ̀lú ọ̀nà kannáà. Nínú ìwé Lúkù orí kẹrin, Sàtánì dán Jésù wò pẹ̀lú àwọn ìpàrọwà tí ó n lò fún wa. Jésù sì fi Sàtánì bú ní gbogbo ìgbà wọ̀nyí.

- Ó dán Jésù wò kí ó lee fihàn dájú pé òun jẹ́ Ọmọ Ọlọ́run, nípa sísọ òkúta di àkàrà, nígbàtí ebi n paá.





- Ó dán Jésù wò pẹ̀lú agbára, pé òun yíò fi àṣẹ ayé yìí lé Jésù lọ́wọ́ bí ó bá lè tẹríba fún òun.
- Ó dán Jésù wò pẹ̀lú ìgbéraga, nípa wípé kí ó fò sọ̀kalẹ̀ láti orí tẹ́mpìlì, láti fi ìwúlò rẹ̀ hàn.
- Sátánì n lo àwọn ọgbọ́n kannáà lórí wa, ó n pàrọwà sí àwọn ohun tí ọkàn wa fẹ́.

### 3. Dá Gbòngbò Ẹ̀ṣẹ̀ Mọ

Sátánì nlo àwọn ohun àfẹ́rí, àwọn ohun tí a ṣàfẹ́rí nínú ọkàn wa, ó sì n yí wa po láti dán wa wò kí á le ṣubú sínú ẹ̀ṣẹ̀. Arákùnrin Roberton McQuilkin ṣe àpèjúwé ètò ẹ̀ṣẹ̀ àti bí ó ṣe yẹ kí á mòye ohun tí à n bá jà.

Njẹ́ o tilẹ̀ ti fi ìgbà ka dúró kí o sì ronú nípa ohun tí ìdánwò jẹ́? Kì í ṣe ohun tí ó burú, kódà, ohun tí ó dára ni, nítorínáà ni ó ṣe n dán ènìyàn wò. Ọlọ́run sì ni ó ṣètò àwọn ohun àfẹ́rí wa. Ọlọ́run dá wa láti gbádùn ara wa, láti ní ohun ìní, láti jẹ́ ohun kan pàtó. Ṣùgbọ́n níṣe ni à n

gbìyànjú láti mú àwọn ohun àfẹ́rí wọ̀nyí ṣe ní ọ̀nà tí kò tọ́. Èyí sì jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀. Nítorínáà, ìgbésẹ̀ tí ó kàn ni láti dá ọ̀tá nì mọ̀, kí á sì ṣe ìyàtọ̀ láàrin ohun tí í ṣe ìdánwò àti èyí tí kìí ṣe ìdánwò. Bí n kò bá dá ọ̀tá mi mọ̀, báwo ni ngó ṣe ja àjàyọrí?

Ìfẹ́ láti gbádùn òúnjẹ, ìbáṣepọ̀, ìsinmi → ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ → ìfẹ́ ara

Ìfẹ́ láti ní ohun ìní → ojúkòkòrò → ìfẹ́ dúkìá

Ìfẹ́ láti jẹ́ ẹni pàtàkì → ìgbéraga → ìjọ ara ẹni lójú

A bí wa pẹ̀lú àwọn ààyò ọkàn, tí Ọlọ́run ṣètò, èyí tí, láìsí rẹ̀, níṣe ni àwa yíò kú àkúrun. Àfẹ́rí wa fún ìbáṣepọ̀, láìsí rẹ, kì yíò sí ọmọ. À n ṣe àfẹ́rí láti jẹun, láìsí èyí, ebi yíò pa wá. A ní àfẹ́rí láti ni àwọn dúkìá, bí aṣọ àti ibùgbé. Gbogbo àwọn ohun wọ̀nyí wà lára ètò ìṣẹ̀dá wa, Ọlọ́run dá ènìyàn pẹ̀lú àwọn ohun àfẹ́rí.

> "Nítorí ohun gbogbo tí n bẹ ní ayé, ìfẹ́kúfẹ̀ ẹ ara, àti ìfẹ́kúfẹ̀ ojú, àti ìrera ayé" 1Jòhánù 2:16

Sàtánì n lo àwọn ohun àfẹ́rí wọ̀nyí, ó sì n mú kí wọ́n dán wa wò sí ẹ̀ṣẹ̀. Nítorínáà a





ní láti mòye, ìdí tí a fi n dá ẹ̀ṣẹ̀, kíni ó n mú wa ṣe bí a ti n ṣe? Njẹ́ a kórìíra ẹnikẹ́ni, nítorí pé à n jowú ohun ìní tàbí ìwúlò wọn? Ṣe Sàtánì n dán wa wò pẹ̀lú ìmúlò wa fúnra wa, tí ó sì n pàrọwà sí ìgbéraga wa?

Njẹ́ àwá tilẹ̀ gbàgbọ́ nítòótọ́ pé Ọlọ́run tó láti fún wa ní àwọn ohun tí a nílò tí a sì ṣàfẹ́rí? Nígbàtí a bá dá ẹ̀ṣẹ̀, a kúrò nínú ìfẹ́ Ọlọ́run fún ayé wa, a sì n tẹ́ ara wa lọ́run ní kikọ ìpèsè Ọlọ́run. Èyí ni orísun ẹ̀ṣẹ̀ wa. Ìsráẹ́lì nínú ẹ̀ṣẹ̀ wọn gbogbo, wọn kò gba Ọlọ́run gbọ́ wípé Òún lè tú wọn sílẹ̀, ní kété tí wọn kò ti ní ìgbàgbọ́ nínú agbára Ọlọ́run, ohun gbogbo ìyókù tẹ̀le.

Fún wa láti bẹ̀rẹ̀ sí ja gun yìí, a ní láti dá àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa mọ̀, àwọn ohun tí ó n fà wá sẹ́yìn láti jẹ́ ajagun ti ẹ̀mí tí Ọlọ́run nfẹ́.

| | Gbongbo Ẹ̀ṣẹ̀ | Àwọn Ìdánwò | Bí mo ṣe n dáhùn nínú ẹran ara |
|---|---|---|---|
| 1. | Àwọn ìdánwò wo ni mo ní nínú ẹran ara mi tí Ọlọ́run kò lè dunnú sí? | | |
| 2. | Àwọn ohun ìní wo ni mo nṣe ojúkòkòrò rẹ̀? | | |
| 3. | Kíni àwọn ohun tí à n dán mi wo láti gbéraga nípa? | | |

## Ọ̀nà Ìdodimú/Ìgbèja Ara Ẹni

A ní láti mọ̀ wípé à n bá wa jà ní gbogbo ìgbà, àwọn ààyè púpọ̀ mìíràn wà láti dán wa wò, kódà ju àtẹ̀yìnwá lọ. Ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán, ike ayàwòrán DVD, ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì, ìwé ìròyìn, àwọn ẹ̀rọ ayélujára oríṣiríṣi, jẹ́ àwọn ohun tí a le yàn fún ìmárayá tí ó n mú ara wa yá gágá. Lónìí, kò ṣòro láti fà wá sínú àìbìkítà ti ẹ̀mí, kí á máṣe funra nípa ìjàkadì ti ẹ̀mí tí ó n wáyé.

Nínú ogun, àwọn ọ̀nà ìdodimú àti ti ìjagun wà, èyí náà ni ó wà nínú ogun ti ẹ̀mí. Ní ayé àtijọ́, kí ó tó di wípé a ní àwọn èrọ tí n ṣe àmì àti ẹ̀ṣọ́, níṣe ni a máa n kọ́





ilú ní ọ̀nà tí ààyè ìdodimú/ìgbèjà ara yíò wà. Àwọn ògiri jẹ́ ọ̀nà kan, àwọn ilé iṣọ náà sì jẹ́ ọ̀nà mìíràn. Àwọn ilé isọ máa n jẹ́ kí á ríran rí òkèèrè láti mọ̀ bí ọ̀tá bá n bọ̀, kí wọ́n sì lè ṣe ìkìlọ̀ fún àwọn ará ilú tàbí kí wọ́n ránṣe sí àwọn ilé iṣọ mìíràn. Nípa èyí, gbogbo ìlú yíò ti wà ní ìmúrasílẹ̀ fún ìjàmbá kí ìjàmbá. Àwọn ògiri jẹ́ ọ̀nà láti gba àwọn ènìyàn wọlé sínú ilú nípasẹ̀ àwọn ojú ọ̀nà ìlẹ̀kùn tí a ti ṣètò.

Bí àwọn ilú àtijọ́ ti ṣe ní ọ̀nà ìlàkalẹ̀ fún ìgbèja ara wọn, bẹ́ẹ̀ ni àwa náà yẹ kí á ronú nípa ìgbèjà ara ti ẹni. À n bá wa jà nínú ẹ̀mí, báwo ni a ó ṣe gbèjà ara wa? Ní kété tí a bá ti dá àwọn ibi tí a ti jẹ́ aláìlágbára tó mọ̀, a ní láti fi agbára wọ àwọn ẹ̀yà náà nínú odi/ògiri wa. Bí a bá ri pé à n wo àwọn ètò tí kò fi ìdí ẹ̀mí Ọlọ́run múlẹ̀, a ní láti bèèrè, tani à n gbà láàyè láti wọ inú ìlú wa. Ìkọlù ti bẹ̀rẹ̀ sí ṣẹlẹ̀. Bákannáà ni ó ṣe jẹ̀ fún àwọn ẹ̀rọ ayélujára, asọ̀rọ̀mágbèsì àti ìwè ìròyìn pẹ̀lú. Àwọn àwòrán àti ìrònú wo ni ò n wọ

inú ọkàn wa tí Sàtánì le lò láti fi dán wa wò sínú ẹ̀ṣẹ̀?

Iṣẹ́ àwọn ilé iṣọ ni láti sọ́nà fún àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó dàbí ìjàmbá kí wọ́n tó di ìjàmbá gidi. Àwa náà nílò ilé iṣọ tiwa fúnra wa, a gbọ́dọ̀ máa wọ̀nà fún àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ bí ìjàmbá, kí á ba lè dáhùn sí wọn kí wọ́n tó ṣẹlẹ̀ yàtọ̀ sí nígbà tí wọ́n bá ti ṣẹlẹ̀ tán. A ó fẹ́ fún Sàtánì ní ààyè láti bẹ̀rẹ̀ ìjàkadì rẹ̀. Àwọn ohun ìjà ìgbèjà ara ẹni:

**1. Bíbélì**

Jésù ṣe àpẹẹrẹ fún gbogbo onígbàgbọ́, nígbàtí Sàtánì kojú rẹ̀ lórí òkè ìdánwò. Jésù, ẹnití o le yàn láti lo ohun ìjà kí ohun ìjà tí òún bá fẹ́. Ṣùgbọ́n ó dá Sàtánì lóhùn àwọn ìdánwò rẹ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Sàtánì dán Jésù wò, òún sì dáa lóhùn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.

Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ti Jésù lò, dá àwọn ìdánwò Sàtánì lóhùn, ohunkóhun yówù tí ìdánwò wa leè jẹ́, a le wo inú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run láti gbèja ara wa lọ́wọ́ ìjà Sàtánì.





Bí a bá ní ìṣòro pẹ̀lú ìdánwò àgbèrè tàbí panṣágà, a lè kọ́ ohun tí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ nípa rẹ̀. A tún le ṣe àkásórí àwọn ẹsẹ bíbélì láti ràn wá lọ́wọ́ pẹ̀lú ìṣòro wa. Bí a bá ní ìṣòro pẹ̀lú ìgbéraga, a lè ṣe bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́. Ní kété tí a bá ti mọ ìṣòro wa, a wá le gbógun ti ìṣòro náà pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.

Kọ àwọn ìdánwò rẹ sílẹ̀ àti ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí yíò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti borí wọn.

| Ìdánwò | Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run | Ẹsẹ Àkọ́sórí Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run |
|---|---|---|
| | | |
| | | |
| | | |

**2. Àdúrà**

A tún lè gbé ìṣòro náà lọ sọ́dọ̀ Ọlọ́run fúnra Rẹ̀, a lè gbàdúrà fún ìtúsílẹ̀ lọ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ àti ìdánwò tí ó dúró tì wá. Jésù náà ṣe èyí. Nínú gbogbo ènìyàn tí kò yẹ kí ó gbàdúrà rárá, Jésù ìbá jẹ́ ọ̀kan, ṣùgbọ́n bí Jésù bá lè gbàdúrà, báwo ni ó ṣe yẹ kí tiwa kí ó pọ̀ tó?

Nígbàtí Jésù n kojú ìṣẹ̀lẹ̀ Júdásí àti ìyà orí igi àgbélèbú, òun fúnra rẹ̀ gbàdúrà nínú ọgbà, òógùn ara rẹ̀ sì dàbí ẹ̀jẹ̀. O lè kọ́ àdúrà tí ó dojúkọ ìṣòro rẹ sílẹ̀ kí o sì mu tọ Olúwa lọ.

**3. Ìjọ Ọlọ́run**

Àwọn onígbàgbọ́ ni ó wà nínú ìjọ, lọ́mọdé àti àgbà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú ìjọ ni ó ti ní ìrírí ohun tí ó n ṣẹlẹ̀ sí ẹnìkọ̀ọ̀kan wa lónìí. Ọlọ́run n fi ẹ̀bùn fún ara nítorí ìdí èyí pàápàá. A le gbé ìṣẹ̀lẹ̀ náà tọ àwọn olùṣọ́ àgùntàn tàbí olùdámọ̀ràn tí ó le darí wa nínú ìṣòro náà.

Bákannáà, a ó tun wá ẹnití ó n ronú bákannáà bí tiwa, ẹnití ó n wá òdodo, kí a sì rọ̀ wọ́n láti jẹ́ ẹnikejì wa nínú àdúrà. Wá ẹnìkan tí yíò ní ìfẹ́ sí àláfíà ẹ̀mí rẹ, kí ẹ sì máa pàdé fún àdúrà àti ìrànlọ́wọ

## Ọ̀nà Ìjagun/Ìgbógun

Ọ̀nà ìgbógun túmọ̀ sí kí á gbé ogun tọ ọ̀tá wa lọ. O mọ̀ wípé o ní ọ̀tá, èhá ti ṣe tí ìwọ yíò wá dúró de ọ̀tá rẹ láti dojú kọ ọ́?





Ìdáhùn wa kò ṣe dandan kí ó jẹ́ lẹ́yìn tí a ti dojúkọ wá. A ó ní láti dúró di ìgbà tí a bá tó ní àwọn ìrírí ibi, a lè ri mọ wípé wọn kò farahàn rárá.

Ìbéèrè tí a ní láti béèrè ni pé báwo ni ó ṣe káwa lára sí láti jẹ́ ohungbogbo tí Olúwa fẹ́ kí á jẹ́? Njẹ́ a ṣetán láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó nira? Yọ gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣeéṣe kúrò; gba ààyè ẹ̀tàn kúrò lọ́wọ́ Sàtánì.

## Àwọn ohun ìjà ìgbogun

**1. Bíbélì**

A ko gbọ́dọ̀ má ka ọ̀rọ̀ Ọlọ́run láti kojú ìṣòro ti agbára wa kò gbé nìkan, idà ti ẹ̀mí ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, ó jẹ́ ohun ìjà ìgbógun. Kíka bíbélì ní ojojúmọ́ ràn wá lọ́wọ́ láti mòye ìfẹ́ Ọlọ́run nínú ayé wa, ó sì n gbáradì fún àwọn ìkọlù tí a dojú rẹ̀ kọ wá.

**2. Àdúrà**

Lẹ́ẹ̀kansi, àdúrà wa kò yẹ kí ó jẹ́ fún ìgbèjà ara nìkan, a lè béèrè pé kí Olúwa fún wa ní odi ààbò, kí á ba lè ní ìṣẹ́gun

lórí àwọn ìdánwò náà kí wọ́n tilẹ̀ tó fi ara hàn. A lè gbé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ wa lọ síbi itẹ́ Ọlọ́run.

**3. Àwẹ̀ Gbígbà**

Àwẹ̀ gbígbà fi ààyè sílẹ̀ fún wa láti kó ara àti ọkàn wa ní ìjánu, bí jagunjagun tí ó wà ní ìmúrasílẹ̀. Nípa àwẹ̀ gbígbà a lè rí bí ìṣẹ̀lẹ̀ náà ti tóbi tó, báwo ni ebi òdodo ṣe n pa wá sí yàtọ̀ sí oúnjẹ ti ayé yìí?

**4. Ṣíṣe Àṣàrò**

Jésù ṣe àṣàrò ó sì mọ àwọn ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sórí. Kíni àwa náà ò ṣe lè ṣe bẹ́ẹ̀? Kí ó tó di pé a dojúkọ wá rárá, ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí ó wà nínú wa yíò mú wa wà ní ìmúrasílẹ̀ fún ìkọlù ìgbàgbogbo lórí ọkàn wa.



ORÍ KARÙN-ÚN

# ÌFỌWỌ́SOWỌ́PỌ̀ TI Ẹ̀MÍ

O ní láti mòye wípé ọ̀tá tí ò n bá jagun, ìyẹn èṣù, n ṣiṣẹ́, ó sì n jà nípa lílo ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ti ẹ̀mí, èyí tí ó ga tí ó sì lágbára púpọ̀.

Ìpele ara mẹ́rin ni ó wà nínú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ti ẹ̀mí èṣù gẹ́gẹ́bí Efésù 6:12 ṣe sọ.

> "Nítorípé kìí ṣe ẹ̀jẹ̀ àti ẹran-ara ni àwá n bá jìjàkadì, ṣùgbọ́n àwọn ìjòyè, àwọn ọlọ́lá, àwọn aláṣe ibi òkùnkùn ayé yìí, àti àwọn ẹ̀mí búburú ní ojú ọ̀run." Efésù 6:12

**1. Ìjòyè**

Àwọn wọ̀nyí jẹ́ àwọn àṣẹ tí ó wà ní àyíká nínú ìjọba òkùnkùn lórí àwọn orílẹ̀-èdè. Ninú ìwé Danieli 10:12-21.

"Nígbànáà ni ó wí fún mi pé, má bẹ̀rù, Daniẹli: láti ọjọ́ kinní tí ìwọ ti fi àyà rẹ si láti mọ́ye, tí ìwọ sì npọ́n ara rẹ̀ lójú níwájú Ọlọ́run rẹ, a gbọ́ ọ̀rọ̀ rẹ, èmí sì wá nítorí ọ̀rọ̀ rẹ. 13.Ṣùgbọ́n balógun ìjọba Persia nì dè mí ní ọ̀ná ní ọjọ́ mọ́kànlélógún: ṣùgbọ́n wòó, Mìkaẹli, ọ̀kan nínú àwọn olórí balógun wá láti ràn mí lọ́wọ́, èmí sì di ipò mi mú lọ́dọ̀ àwọn ọba Persia. 14. Njẹ́ nísisìyí, mo dé láti mú ọ mòye ohun tí yíò bá àwọn ènìyan rẹ ní ìkeyìn ọjọ́: nítorí tí ọjọ́ púpọ́ ni ìran náà í ṣe. 15.Nígbàtí ó sì ti sọ irú ọ̀rọ̀ báyìí fún mi tán, mo dojúkọ ilẹ̀ mo sì yadi. 16.Sì wò ó, ẹnìkan tí jíjọ rẹ̀ dàbí ti àwọn ọmọ ènìyàn fi ọwọ́ kan ètè mi: nígbànáà ni mo ya ẹnu mi, mo sì fọhùn, mo sì wí fún ẹnití ó dúró tì mí pé, olúwa mi, níti ìran náà, ìrora mi padà sínú mi, èmi kò sì lágbára. 17. Nítorípé báwo ni ọmọ-ọ̀dọ̀ Olúwa mi yìí yoo ti ṣe lè





bá Olúwa mi yìí sọ̀rọ̀? Ṣùgbọ́n bí ó ṣe tèmi ni, lólojúkannáà, agbára kò kù nínú mi, bẹ́ẹ̀ni kò sì ku èémí nínú mi. 18.Nígbànáà ni ẹnìkan tí ó ní àwòrán ènìyàn wá ó sì tún fi ọwọ́ tọ́ mi, ó sì mú mi lára lé, 19. Ó sì wípé, ìwọ okùnrin olùfẹ́ gidigidi, má bẹ̀rù, àlááfíà ni fún ọ, mú ara le, Nígbàtí óun bá mi sọ̀rọ̀, a sì mú mi lára le, mò sì wípé, Kí olúwa mi kí ó má sọ̀rọ̀, nítorítí ìwọ ti mú mi lára le. 20. Nígbànáà ni ó wípé, Ìwọ, ha mọ ìdí ohun tí mo tọ̀ ọ́ wá sí? Nísisìyí ni èmi ó sì yípadà lọ í bá balógun Persia jà: nígbàtí èmí bá sì jáde lọ, kíyèsí i, balógun Hellene yíò wá. 21. Ṣùgbọ́n èmi ó fi èyí tí a kọ sínú ìwé òtítọ́ hàn ọ́: kò sì sì ènití ó ràn mí lọ́wọ́ sí àwọn wọ̀nyí, bíkòṣe Mikaẹli balógun yín." Dan 10:12-21

A fi yé wa bí àdúrà Danieli ṣe ní ìdádúró nìpasẹ̀ balógun Persia títí di ìgbà tí Ọlọ́run rán ángẹ́lì

Michaelí, ọ̀kan nínú àwọn olórí ogun àwọn ángẹ́lì ní ọ̀run, kí èsì àdúrà rẹ̀ tó dé.

**2. Ọlọ́lá**

Àwọn wọ̀nyí ni olórí/adarí ayé, ọkùnrin àti obìnrin ní ipò àṣẹ ní oríṣirísi ìpele nínú orílẹ̀-èdè, tí wọ́n jẹ́ ikọ̀ àti ohun èlò ìparun ní ọwọ́ èṣù. Bí àpẹẹrẹ, àwọn olórí àti àwọn ènìyàn tí ó n ṣàtìlẹyìn jàndùkú àti ìpànìyàn ní gbogbo àgbáyé.

**3. Aláṣẹ ibi òkùnkùn ayé yìí**

Àwọn wọ̀nyí jẹ́ àwọn aláṣẹ ní gbogbo onírúurú ẹgbé bí awo, àjẹ́, oṣó, ògbóni àti àwọn ìkórajọpọ̀ sàtánì bẹ́ẹ̀.

**4. Ẹ̀mí búburú ní ojú ọ̀run**

Àwọn wọ̀nyí jẹ́ ẹ̀mí èṣù, àti onírúurú ipá búburú ti ẹ̀mí tí ó n ṣe ìránṣẹ́ fún àwọn ìpele àṣẹ tí a ti sọ ṣáájú.

**Iṣẹ́ Ìfọwọ́sowọ́pọ̀**

Àwọn ìpele mẹ́rin àṣẹ ẹ̀mí tí ó wà nínú ìjọba òkùnkùn wọ̀nyí máa n ṣiṣẹ́ ní ìfọwọ́ sowọ́pọ̀ láti le mú wa.





O lè má ri wọn nípa ti ara bíkòṣe nípasẹ̀ ojú ti ẹ̀mí nìkan. Ìdí sì nìyí tí wọ́n fi jẹ́ ipá òkùnkùn, ṣùgbọ́n wọ́n n dojú kọ ọ́ ní gbogbo ọ̀nà. Wọ́n n dojú kọ iṣẹ́ rẹ àti oko-òwò rẹ nípasẹ̀ àwọn alájọṣiṣẹ́pọ̀ rẹ tíí ṣe ikọ̀ wọn nínú ibi iṣẹ́ rẹ, wọ́n n dojúkọ ìdílé rẹ nípasẹ̀ àwọn ọmọ tàbí ọmọ ọ̀dọ̀ tí ó n gbé pẹ̀lú rẹ, wọ́n n dojúkọ ìdàgbà ẹ̀mí rẹ nínú ìjọ nípasẹ̀ àwọn ọmọ ìjọ, wọ́n n dojúkọ ọ́ nínú ọjà àti nípasẹ̀ alábágbé rẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ; ibikíbi tí o wà, jẹ́ ibi tí wọ́n ti le dojúkọ ọ́.

Nígbàtí o kò le dènà ìdojúkọ wọn nípa kíkúrò ní ibití ò n gbé àtí pẹ̀lú, nígbàtí kò sí ibi tí o le sápamọ́ sí, ó sàn kí o jà padà kí o sì kojú àwọn tí n dojúkọ ọ́, nígbàtí ó sì ti jẹ́ wípé o ní ẹnìkan tí ó tóbi jù wọ́n lọ láti jà fún ọ, èyí tí í ṣe Jésù Krístì, ìṣẹ́gun rẹ si dájú. Inú mí dùn láti sọ fún ọ pẹ̀lú wípé, ibi gbogbo tí o bá wà, jẹ́ ibi tí ìwọ́ ti le ní ìṣẹ́gun bí ó bá fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ nínú Ọlọ́run.

"Èéṣe tí àwọn orílẹ̀-èdè fi n bínú fùfù, àti tí àwọn ènìyàn fi n gbèrò


asán? 2. Àwọn ọba ayé kẹ́sẹ̀ jọ, àti àwọn ìjòyè ngbìmọ̀ pọ̀ sí Olúwa àti sí Ẹni-òróró rẹ̀ pé, 3. Ẹ jẹ́ kí á fa ìdè wọn já, kí á sì mú okùn wọn kúrò ní ọ̀dọ̀ wa. 4.Ẹnití ó jókò ó ní ọ̀run yíò rẹ́rìn-ín: Olúwa yíò sì yọ ṣùtì sí wọn. 5. Nígbànáà ni yíò sọ̀rọ̀ sí wọn nínú ìbínú rẹ̀, yíò sì yọ wọ́n lẹ́nu nínú ìbìnújẹ́ rẹ̀ kíkan. 6.Ṣùgbọ́n mo ti fi Ọba mi jẹ lórí Síónì, òkè mímọ́ mi. 7. Èmi ó sì ròyìn ìpinnu Olúwa: Ó ti wí fún mi pé, Ìwọ ni Ọmọ mi, lónìí ni mo bí ọ. 8.Bèrè lọ́ wọ́ mi, èmi ó sì fi àwọn orílẹ̀-èdè fún ọ ní ìní rẹ, àtí ìhà òpin ilẹ̀ ní ọrọ̀-ilẹ̀ rẹ. 9.Ọ̀pá irin ni ìwọ ó fi fọ́ wọn; ìwọ ó sì run wọ́n wómú-wómú, bí ohun èlò amọ̀. 10. Njẹ́ nítorínáà kí ẹ̀yin kí ó gbọ́n, ẹ̀yin ọba: kí á sì kọ yín, ẹ̀yin onídàjọ́ ayé. 11. Ẹ fi ìbẹ̀rù sin Olúwa, ẹ sì ma yọ̀ ti ẹ̀yin ti ìwárìrì. 12. Fi ẹnu ko ọmọ náà lẹ́nu, kí o máṣe bínú, ẹ̀yin a sì ṣègbé ní ọ̀nà náà, bí inú rẹ bá ru díẹ̀ kín-ún.





Ìbùkún ni fún gbogbo àwọn tí ó gbẹ́kẹ̀ wọn lé e." Orin Dáfídì 2:1-12.

## Ìjàkadì ti ẹ̀mí pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ èṣù




Nínú ìwé Efésù 6:12, bíbélì sọ wípé kí á gbé gbogbo ìhámọ́ra Ọlọ́run wọ̀, kí á lè borí ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ti ẹ̀mí tí èṣù nlò lòdì sí wa.

Ẹ jẹ́ kí á wo àpèjúwe ìhámọ́ra Ọlọ́run:

a. Lẹ́yìn tí ẹ ti fi àmùrè òtítọ́ di ẹ̀gbẹ́ yín, ẹṣẹ kẹ̀rìnlá - òtítọ́ ni ìfihàn Ọlọ́run, tí a

rí nínú Krístì, tí a sì mọ̀ nínú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.

b. Tí ẹ sì ti di ìgbáyà òdodo nì mọ́ra: ẹsẹ kẹrìnlá - Ọlọ́run ní n fún ni ní òdodo, nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀ Jésù Krístì. Gbogbo àwọn ẹni tí a bí nípasẹ̀ Jésù Krístì sí Ọlọ́run ni ó jẹ́ olódodo.

d. Tí ẹ sì ti fi ìmúra ìhìnrere àláàfíà wọ ẹsẹ̀ yín ní bàtà: ẹse kẹẹ̀dógún - ìhìnrere ni agbára Ọlọ́run fún ìgbàlà sí gbogbo àwọn tí ó gbàgbọ́. Ó jẹ́ ìhìnrere ìjọba Ọlọ́run. Ó jẹ́ ìròyìn ikú, ìsìnkú àti ajínde Jésù.

e. Lékè gbogbo rẹ, ẹ mú apata ìgbàgbọ́: ẹsẹ kẹrìndínlógún, ìgbàgbọ́ ni ìdánilójú ohun tí à n retí, ìjẹ́rìí ohun tí a kò rí. Òun ni ìsopọ̀ láàrin ènìyàn àti Ọlọ́run èyí tí ó mú inú Ọlọ́run dùn.

"Ṣùgbọ́n ní àìsí ìgbàgbọ́, kò ṣe é ṣe láti wù ú; nítorí ẹnití ó bá ntọ Ọlọ́run wá kò lè ṣàì gbàgbọ́ pé ó n bẹ, àti pé òun ni olùṣẹ̀san fún àwọn tí ó fi ara balẹ̀ wá a." Heb 11:6.





Pẹ̀lú ìgbàgbọ́ ìwọ yíò lè pa gbogbo iná ẹni ibi nì run.

ẹ. Kí ẹ sì mú àṣíborí ìgbàlà, ẹsẹ kẹtàdínlógún.

- Àgbélébù Krístì jẹ́ ti gbogbo ènìyàn.
- Àwọn kan rìn kiri pẹ̀lú àṣíborí nìkan.
- Èyí ni ẹ̀bùn tí ó ga jù. "Nítorí ikú ni èrè ẹ̀ṣẹ̀, ṣùgbọ́n ẹ̀bùn ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ni ìyè tí kò nípẹ̀kun, nínú Krístì Jésù Olúwa wa." Rom 6:23
- Ìtúsílẹ̀ rẹ nínú kòtò ọ̀run àpáàdì, èyí tí a ti fọ́ agbára rẹ̀ lorí rẹ ni òún iṣe. O ti di òmìnira lọ́wọ́ èṣù, o ti di òmìnira láti gba ìhìnrere gbọ́, láti fi ògo fún Olúwa nínú òtítọ́, láti gbé ní òdodo àti ìgbàgbọ́ nípasẹ̀ Jésù Krístì, Òun ni ọ̀nà kan ṣoṣo tí ó wà.

f. Àti idà ẹ̀mí, tí í ṣe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, ẹsẹ kẹtàdínlógún - ọ̀rọ̀ náà ni èyí tí n kọ́ ọ, dárí rẹ, tí ó sì n gbà ọ́ níyànjú. Ó yẹ ní èyí tí à n kà, kí o ba lè kọ́ ohun tí ó tọ́ tí ó sì ṣe ìtẹ́wọ́gbà sí Ọlọ́run.

**Kínni ìdí tí o fi gbọ́dọ̀ gbé ìhámọ́ra Ọlọ́run wọ̀?**

a. Kí o má ba wà ní ìhòhò kí o sì gbọ́kàn lé agbára tìre.

b. Kí o ba le wà ní alágbára ni a ṣe fi àwọn ohun ìjà mẹ́fà wọ̀nyí fún ọ, kí o ba le wà ní alágbára nínú ìgbàgbọ́, kí o fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ nínú ìhìnrere, kí o ma gbé inú òtítọ́, kí o sì ní ìṣẹ́gun nípa ìgbàgbọ́.

Ìhámọ́ra Ọlọ́run tí o wọ̀ ni ó n mú ọ wà ní àìléwu àti pẹ̀lú agbára. A ti dán an wò tẹ́lẹ̀, ó sì ti fihàn wípé ó yẹ ní ohun tí a n gbẹ́kẹ̀lé.

Láti gbẹ́kẹ̀lé ìhámọ́ra Ọlọ́run túmọ̀ sí wípé kí á gbẹ́kẹ̀lé Ọlọ̀run tìkararẹ̀, o lè gbẹ́kẹ̀lé ipasẹ̀ Ọlọ́run fún ìjagun, kì í sìí ṣe tìrẹ fúnra rẹ. Ọlọ̀run sá ti fi ọ̀títọ́ Rẹ̀ hàn fún ọ lórí àgbélébù.





**ÀDÚRÀ**

O gbọ́dọ̀ ma gbàdúrà ní gbogbo ìgbà, kí o ba lè ma ní ìgbé ayé ìṣẹ́gun rẹ lọ. Bí a bá gbé gbogbo ìhámọ́ra Ọlọ́run wọ̀ tí a kò sí gbàdúrà, níṣe ni a dàbí jagunjagun tí ó wọ ìhámọ́ra rẹ̀ ṣùgbọ́n tí ó dúró tiri tí kò sì bá ọ̀tá rẹ̀ jà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé ọ̀pọ̀ ọta àti ọfà ni ó n fò kọjá lẹ́gbẹ̀ ẹ́ rẹ̀. Bí irú ẹni bẹ́ẹ̀ kò bá ṣọ́ra, ọ̀tá lè ri mú kí ó sì ta á lọ́fà. A ní láti gbàdúrà.

a. Ní gbogbo ìgbà nínú ẹ̀mí: Èyí kò túmọ̀ sí pé a n gbàdúrà ní gbogbo ìṣẹ́jú, ṣùgbọ́n, ó túmọ̀ sí pé à n gbàdúrà nínú ìṣẹ̀lẹ̀ àti ìṣòro gbogbo, bóyá kékeré tàbí títóbi. Kọ́ láti fi ohun gbogbo lé Ọlọ́run lọ́wọ́, kì o sì gbàdúrà nípa ohun gbogbo. Èyí ni ẹ̀yà ibi tí a ti máa n fi ààyè fún éṣù láti dojúkọ wá nítorí àìbìkítà wa ní rírò wípé àwọn ohun kan kò nílò àdúrà tàbí fífi wọ́n lé Ọlọ́run lọ́wọ́.

b. A ní láti gbàdúrà pẹ̀lú sùúrú gbogbo: Èyí túmọ̀ sí wípé o ní láti tẹ̀síwájú

nínú àdúrà nì pàápàá bí ó ti dàbí wípé o kò rí ìdáhùn tàbí tí ìdáhùn tí o rí kò dàbí èyítí ò n retí. Wo Dánielì nínú ìwé Daniel 10:12-21.

Ó túbọ̀ n gbàdúrà títí tí Ọlọ́run fi dásí ọ̀rọ̀ rẹ̀ tí òún sì rí ìdáhùn àdúrà rẹ̀ gbà ju bí òún tilẹ̀ ti gbàdúrà lọ.

d. A ní láti gbàdúrà fún gbogbo ènìyàn mímọ́: Njẹ́ ìwọ́ n gbàdúrà fún àwọn arákùnrin àti arábìnrin rẹ nínú Krístì bí? Njẹ́ o n gbàdúrà fún àwọn tí n ṣe àkóso ìjọ bí? Njẹ́ ìwọ́ n gbàdúrà fún àwọn olùṣọ́ àgùntàn rẹ bí?

Láti inú àlàyé ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ti ẹ̀mí, èyí tí a ti ṣe síwájú, a ti ri wípé èṣù le ṣiṣẹ́ nípase ọ̀nàkọnà láti rí wa mú, kódà nípa àwọn ará tí wọn kò ní agbára nínú ẹ̀mí tàbí tí wọn kò kọbiara nínú ìjọ. Ìdí nìyí tí a fi gbọ́dọ̀ máa gbàdúrà fún wọn pé ní èyí tí èṣù ìbá fi lò wọ́n lòdì sí wa, Ọlọ́run yíò lò wọ́n fún ire wa. O ní láti gbàradì kí o sì wà níwájù èṣù nínú ogun ẹ̀mí yìí.





d. Máa gbàdúrà fún àwọn òbí rẹ àti àwọn ènìyàn ní àyíká rẹ: Gbàdúrà kí o fi ọkàn àwọn ọ̀gá rẹ ní ibi iṣẹ́ lé Ọlọ́run lọ́wọ́, àwọn alájọṣiṣẹ́ rẹ, àwọn ẹbí rẹ, àwọn alájọgbé rẹ àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ.

**Ṣe àkíyèsí:** Bí o bá ti ṣe gbà àwọn wọ̀nyí fún Ọlọ́run sí ni o ṣe n ṣètò ààyè ìsinmi fún ara rẹ ní gbogbo ọ̀nà, nítorípé éṣù kò ní le lò wọ́n lòdì sí ọ nípasẹ̀ ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ẹ̀mí òkùnkùn rẹ̀.

ORÍ KẸFÀ

# ÀWỌN ỌMỌ OGUN ỌLỌ́RUN FÚN OGUN ẸMÍ

Bíbélì wípé "Ológun ni Olúwa, Olúwa ni orúkọ rẹ̀." Eksodu 15:3

Ìjọba Ọlọ́run wà ní ìwọ̀yá ìjà ojojúmọ́ pẹ̀lú ìjọba sàtánì láti pa ìdojúkọ àti àyínìpo wọn run lórí ọkùnrin àti obìnrin kí á lè tú wọn sílẹ̀ láti inú ìjọba òkùnkùn wá sí inú ìjọba ìmọ̀lẹ̀.

> "Ẹnití ó ti gbà wá kúrò lọ́wọ́ agbára òkùnkùn, tí ó sì ṣí wa nípò sínú ìjọba àyànfẹ́ ọmọ rẹ̀." Kol 1:13

Gbogbo ẹnití ò bá gba Jésù gẹ́gẹ́bí Olúwa àti Olùgbàlà tí ó sì di àtúnbí ni Ọlọ́run ti gbà sínú ẹgbẹ́ ogun Rẹ̀. Jésù ni balógun àgbà nínú ẹgbẹ́ ogun Ọlọ́run. Àwa ni balógun ní àwọn ipele ìjagun gbogbo.





Nínú ayé, ẹgbẹ́ ogun ní àwọn oríṣi ìpele àti ìwọ̀n, èyítí àwọn balógun n darí wọn fún ìdojúkọ àwọn àyíká kọ̀ọ̀kan àti ìdábòbò. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, gbogbo ìjọ Ọlọ́run tí ó fi gbòngbò múlẹ̀ nínú òtítọ́ àti ààyè ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ni a le fi wé àwọn oríṣi ìpele àti ìwọ̀n, èyítí àwọn balógun n darí wọn. Àwọn balógun wọ̀nyí ni ìránṣẹ́ Ọlọ́run ti Ọlọ́run tí pè láti dá àwọn ìjọ wọn sílẹ̀.

Nínú ẹgbẹ́ ogun yòówù kí o wà, o ní láti tẹ̀lé ìlànà nípasẹ̀ balógun ẹgbẹ́ rẹ (olúṣọ́-àgùntàn rẹ) èyítí balógun àgbà fi lélẹ̀ tí í ṣe Jésù Krístì.

Àwọn ọmọ ogun jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ènìyàn tí ó gba ìbáwí jù, nítorípé wọ́n ti fi ẹ̀mí wọn lélẹ̀ láti jà àti láti dábò bo orílẹ̀-èdè wọn. Wọ́n ti fi gbogbo ìdíwọ́ àti ìdènà sí ẹ̀gbẹ́ kan, wọ́n sì ti lọ fún ìgbáradì tí ó lágbára nítorípé kò sí ààyè fún àṣìṣe ní ojú ogun. Bẹ́ẹ̀ náà ni ó ti rí nínú ẹgbẹ́ ogun Ọlọ́run, kò sí ààyè fún àṣìṣe.

> "Kò sí ẹnití n jagun tí í fi ohun ayé yìí dí ara rẹ̀ lọ́wọ́, kí ó lè mú inú

ẹnití ó yàn án ní ọmọ-ogun dùn." 2Tim 2:4

A gbọ́dọ̀ ṣe ohun gbogbo láti wu ẹni náà tí ó ti pè wá láti jẹ́ ọmọ ogun rẹ.

Ọ̀nà kan ṣoṣo ni ó sì wà fún wa láti wu ẹni tí ó ti pè wá láti jẹ́ ọmọ ogun rẹ̀, ọ̀nà yìí sì ni ìgbọràn. Ìwà ìgbọràn tí ó kù díẹ̀ kí ó pé sì jẹ́ àìgbọràn ní kíkún sí Ọlọ́run. Ọlọ́run n fẹ́ láti ọ̀dọ̀ wa, kí á gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ àti ìkìlọ̀ Òun ní kíkún. A ní láti tẹ̀lé ìlànà/ìkìlọ̀ balógun àgbà wa bí a bá fẹ́ yege nínú àwọn ogun ẹ̀mí wọ̀nyí.

"Bí ẹnikẹ́ni bá sì n jà, a kì í de ní adé, bíkòṣepé ó bá jà ní àìṣe ẹrú." 2Tim 2:5

Ìgbọràn sàn ju ẹ̀bọ lọ.

"Samuẹli sì wípé, Olúwa ha ní inúdídùn sí ọrẹ sísun àti ẹbọ bi pé kí á gba ohùn Olúwa gbọ́? Kíyesí I, ìgbọràn sàn ju ẹbọ lọ, ìfetísílẹ̀ sì sàn ju ọ̀rá àgbò lọ." 1Sam 15:22b





## TANI Ó N DARÍ RẸ NÍNÚ OGUN AYE RẸ?

Báwo ni o ṣe ní ìdánilójú sí wípé Jésù Krístì Olúwa tí í ṣe balógun àgbà ni ó n darí rẹ? Njẹ́ ó dá ọ lójú wípé kì í ṣe àfẹ́rí ohun ìní rẹ ni ó n darí rẹ, àfẹ́rí láti ní orúkọ àti àwọn àfẹ́rí rẹ láti gbádùn ayé, àwọn èyítí ó lòdì sí ìpinnu Ọlọ́run fún ayé rẹ.

Ọmọ ogun ni ọ́, láìsí iyèméjì, ṣùgbọ́n irú ọmọ ogun wo ni ìwọ í ṣe? Njẹ́ ìwọ́ jẹ́ irú ọmọ ogun èyí tí o n tẹ̀lé ìkìlọ̀ láti ọ̀dọ̀ Jésù, ẹnití í ṣe balógun àgbà? Bí ó ti wù kí ọmọ ogun kan kí ó tóbi tó nínú ẹgbẹ́ ogun, bí kò bá tẹ̀lé ìkìlọ̀ ní ojú ogun, bí ó ti wù kí ìkìlọ̀ náà kéré tó, ó le jẹ ìyà rẹ̀ kódà pẹ̀lú ẹ̀mí òun tìkalára rẹ̀.

A gbọ́dọ̀ gbé àwọn ẹrù wíwo àti àwọn ẹ̀ṣẹ̀ tí n so mọ́ ènìyàn, tí kìí jẹ́ kí á fojúsun Ọlọ́run, kí á sì wà ní ìmúrasílẹ̀ gẹ́gẹ́bí ọmọ ogun rere sílẹ̀.

"Nítorínáà bí a ti fi àwọsánmà tí ó kún tó báyìí fún àwọn ẹlẹ́rìí yí wa ká, ẹ jẹ́ kí á pa ohun ìdíwọ́ gbogbo

tì sí apákan, àti ẹ̀ṣẹ̀ rí ó rọrùn jù láti dì mọ́ wa, kí á sì fi sùúrù súré ìje tí a gbé ka iwájú wa." Heb 12:1

"Nítorínáà, ẹ fi àrankàn gbogbo lélẹ̀ ní apákan, àti ẹ̀tàn gbogbo, àti àgàbàgebè, àti ìlara, àti sísọ ọ̀rọ̀ búburú gbogbo." 1Pet 2:1

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ Krístẹ́nì wà lónìí tó jẹ́ akọni nínú Olúwa, ṣùgbọ́n tí wọn sì n jìjàgbara pẹ̀lú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ tí ó rọrùn láti so mọ́ ni. O ní láti yẹ ara rẹ wò ní ìkọríta yìí, kí o sì wo ìdúró rẹ nínú Olúwa. Njẹ́ ìwọ́ n ṣe ohunkohun láti wu Ọlọ́run tàbí ènìyàn. Bí o ṣe n sọ̀rọ̀, bí o ṣe n wọṣọ.

Àwọn ohun wọ̀nyí ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ Krístẹ́nì kò kọbiara sí, kódà nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bá n mú wọn lọ́kàn nípa irú ìmúra tí wọn wọ̀, èyí tí kò wu òun. Bí o kò bá tẹ̀lé ìkìlọ̀ Ọlọ́run àti ìdarí Rẹ̀ nípasẹ̀ Ẹ̀mí Rẹ̀ lórí àwọn ohun kékèké bí ìmúra rẹ, báwo ni o ṣe fẹ́ kí Òun kí ó darí rẹ nínú àwọn ohun nlá? Àwọn ọ̀nà míràn tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ Krístẹ́nì máa n wọ inú ìgbèkùn ni nípa ìṣọ̀rọ̀batẹnijẹ́, ríro ẹjọ́, àtí ìsọ̀rọ̀ẹnilẹ́yìn.





Ó yani lẹ́nu láti rí iye àkókò tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ Krístẹ́nì n lò láti sọ̀rọ̀ ẹni lẹ́yìn, láti ma ro ẹjọ́ àti láti ma sọ̀rọ̀ ìbatẹnijẹ́ nípa àwọn ẹlòmíràn.

Àwọn wọ̀nyí jẹ́ ibi gíga tí ìjọba òkùnkùn n lò láti dá ihò sílẹ̀ nínú ayé onígbagbọ̀ nípasẹ̀ èyítí okun rẹ nínú Olúwa yí ò fi dínkù.

## ÌPELE WO NI O WÀ NÍNÚ IPÒ ẸGBẸ́ OGUN ỌLỌ́RUN?

Ẹni tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ gbà wọlé sínú ẹgbẹ́ ogun lónìí kì yíò wà ní púrúntù títí láíláí. Balógun nínú ẹgbẹ́ ogun lónìí, tí wà ní púrúntù nígbà kan rí. Ṣùgbọ́n pẹ̀lú ìfaraẹnijì, ìbáwí àti ìgbọ́ràn ní kíkún sí àwọn ìkìlọ̀ gẹ́gẹ́bí ọmọ ogun, òun fúnrarẹ̀ gòkè títí tí ó fi di balógun.

O kò le wà ní ọmọdé ọmọ ogun, kí o sì ma retí láti le lo àwọn ohun ìjà ìjagun tí ó lágbára àti láti borí ogun nlánlá. Ipò rẹ nínú ọmọ ogun ni yíò sọ irú ogun tí o lè kápá.

Bí o ti n dàgbà nínú ọjọ́ orí, nípa ti ara, nípa ti èrò inú tí ò sì n bí síi nínú ẹbí rẹ, bí o bá ṣe ìgbéyàwó, o gbọ́dọ̀ dàgbà nínú ẹ̀mí bákannáà, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, àìdọ́gba yíò wà, o sì lè fi ara rẹ sí ipò tí ọ̀tá yíò fi rẹ́ ọ jẹ.

Njẹ́ o sì wà ní ìpele kannáà tí o wà nínú ẹ̀mí ní ọdún tí ó kọjá, ọdún méjì tàbí márùn-ún sẹ́yìn? Ọmọ ogun tó jẹ́ pé ìbọn kékeré nìkan ni o mọ̀ láti lò, tí kò sì tí ì mọ bí a ti n lo àwọn ohun ìjà nlánlá mììràn le wà ní ìṣòro bí ó bá bá ara rẹ̀ nínú ìṣẹ̀lẹ̀ èyítí òun yíò nílò àwọn ohun ìjà nlánlá èyítí òun kò mọ̀ bí a ti í lò.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun ìjà ni ó wà fún wa láti lò nínú Ọlọ̀run fún àwọn ogun ẹ̀mí wa bi Krístẹ́nì. Àwọn ohun ìjà wọ̀nyí ni orúkọ Jésù, ẹ̀jẹ̀ Jésù, òróró, ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ míràn, gẹ́gẹ́bí ẹ̀mí Ọlọ́run bá ti ṣe fi òye àti ìfihàn fún wa.

Ìgboyà àti àṣẹ láti lo àwon ohun ìjà wọ̀nyí dáradára níṣe pẹ̀lú ìpele tí o bá wà ní ipò nínú ẹgbẹ́ ogun Ọlọ́run.





Nítorínáà, o gbọ́dọ̀ jẹ́ kí ọkàn rẹ kó dàgbà, kí o sì sún kúrò ní ìpele ògo kan sí òmíràn, kí o ba lè gbádùn ìrírí nlánlá.

> "Ṣùgbọ́n ìgbàgbọ́ wa nwo ògo Ọlọ́run láìsí ìbòjú bí ẹnipé nínú àwo-jíjí, a sì n pàwàdà sí àwòrán kannáà láti ògo dé ògo, àní bí láti ọ̀dọ̀ Olúwa tí ṣe Ẹ̀mí." 2 Kor 3:18

ORÍ KEJE

# NÍ ÌPARÍ, ÌṢẸ̀GUN DÁJÚ

Ní ṣíṣe àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ inú ìwé yìí tí ó dá lórí jíja ogun ayé rẹ, màá fẹ́ lo ìfiwé ọmọ ogun àti jagunjagun bí mo ti n lò ó bọ́ nínú ìwé yìí, láti fi hàn ọ́, ọ̀nà ìṣẹ́gun ti Ọlọ́run nínú ogun ẹ̀mí.

### Di Ọmọ Ogun fún Krístì nínú Ìjọba Rẹ̀

À n pe ọmọ ogun ní ọmọ ogun nítorí pé ó n mú àwọn ohun tí a nretí láti ọ̀dọ̀ rẹ gẹ́gẹ́bí ọmọ ogun nínú ẹgbẹ́ ogun ṣe ni. A kò pè é ní ọmọ ogun nípa ṣíṣe àfẹ̀rí tàbí nípa wíwọ aṣọ ọmọ ogun nìkan (òun kò tilẹ̀ le wọ̀ ọ́ nítorípé kò yẹ ní ẹnití ó le ṣe bẹ́ẹ̀ bí ó bá dan wò tí ọwọ́ bá sì tẹ̀ẹ́, ó wọ gàù nìyẹn).

A ti gbọ́dọ̀ gbà á wọlé kí ó sì ti lọ fún àwọn ẹ̀kọ́ ìgbáradì láti di ọmọ ogun.

Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, o kò lè di ọmọ ogun nínú ẹgbẹ́ ogun Ọlọ́run bí o kò bá fi ayé rẹ fún





Krístì Jésù, kí o sì fi ṣe Olúwa àti Olùgbàlà ọkàn rẹ. O ní láti kọ́kọ́ ronúpìwàdà kúrò nínú ọ̀nà búburú rẹ kí o sì kọ̀ wọ́n sílẹ̀, kí o sì mú ọ̀nà òdodo rẹ kí o sì tẹ̀lé e. Nígbà yẹn nìkan ni o tó kún ojú òṣùwọ̀n láti jẹ́ ọmọ ogun to n jagun fún Olúwa. Ní kété tí o bá ti fi ayé rẹ fún Jésù Krístì tí o sì di àtúnbí, o ti di ara ẹgbẹ́ ogun Ọlọ́run gẹ́gẹ́bí ọmọ ogun Rẹ̀.

Nítòótọ́ o sì lè jẹ́ ọmọdé ọmọ ogun tàbí púrúntù, ṣùgbọ́n o ti gbé ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ láti di balógun nínú ẹgbẹ́ ogun Ọlọ́run. Bí a ti ṣàlàyé síwájú nínú ìwé yìí, àwọn ìjọba méjì ni ó n ja ìjàkadì ní ojojúmọ́, kòdà ní ìṣẹ́jú ìṣẹ́jú. Ìjọba ìmọ́lẹ̀ èyí nì tí ìjọba Ọlọ́run àti ìjọba òkùnkùn tí í ṣe ti Sàtánì. Gbogbo ènìyàn tí ó wà ni ayé wà ní ọ̀kan nínú àwọn ìjọba wọ̀nyí bóyá ó fẹ́ tàbí ó kọ̀. O ní ànfàní láti yan èyí tí o fẹ́ wà, ṣùgbọ́n o kò lè ṣàì wà ní ọ̀kan.

Bí o kò bá sọ jádé wípé o jẹ́ ti Jésù nípa fífi ayé rẹ fun, kí o sì di àtúnbí, èyí ni wípé o wà nínú ìjọba ti Sàtánì.

"Nígbàtí ilẹ̀ sì mọ́, èmimì díẹ̀ kọ́ ni ó wà láàrin àwọn ọmọ-ogun pé, níbo ni Peteru gbé wà." Ìṣe Àwọn Àpóstélì 12:18

"Ẹnití ó ti gbà wá kúrò lọ́wọ́ agbára òkùnkùn, tí ó sì ṣí wa nípò sínú ìjọba àyànfẹ́ ọmọ rẹ̀." Kol 1:13

Ẹ̀mí Mímọ́ (a tóka rẹ̀ gẹ́gẹ́bí ọmọ ogun)

"Nítorínáà bí ẹnikẹ́ni bá wà nínú Krístì, ó di ẹ̀dá titun, ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; kíyèsí i, wọ́n sì di titun." 2Kor 5:17

Gẹ́gẹ́bí atọ́ka ti ṣe jẹ́ sí ọmọ ogun fún ìtọ́ni àti ìtọ́nà ní ọ̀nà tí òun yíò lò, bẹ́ẹ̀ náà ni Ẹ̀mí Mímọ́ ṣe jẹ́ sí ọnígbàgbọ́.

Lẹ́yìn tí o ti di àtúnbí, o ní láti mọ̀ kí o sì dámọ̀ ìlò àti ìwàláàyè Ẹ̀mí Mímọ́ nínú ayé rẹ. O ní láti kún fún Ẹ̀mí Mímọ́ nítorí láìsí rẹ̀, o kò lè ṣe ohun kan.

"Èmi ni àjàrà, ẹ̀yin ni ẹ̀ka. Ẹnití ó n gbé inú mi, àti èmi nínú rẹ̀, òun ni yíò so èso ọ̀pọ̀lọpọ̀: nítorí ní yíyara





yín kúrò lọ́dọ̀ mi, ẹ kò lè ṣe ohun kan." Johanu 15:5

Bíbélì sọ nínú 2Kor 5:17 pé o ti wà nínú íjọba titun ti ìmọ́lẹ̀, èyí tí o kò mọ̀ tẹ́lẹ̀, o nílò ìtọ́ni lórí bí ìwọ yíò ti rìn, sọ̀rọ̀, sáré, fò àti wípé kínni àwọn ẹ̀tọ́ rẹ, àwọn ohun tí ìwọ kò gbọ́dọ̀ ṣe àti àwọn ohun tí à n retí lọ́wọ́ rẹ.

Ẹnìkan ṣoṣo tí ó kún ojú òṣùwọ̀n láti kọ́ ọ ni pípé àti ní ọ̀nà tí ó dunjú ni Ẹ̀mí Mímọ́ Ọlọ́run. Láìsí rẹ̀, o kò tilẹ̀ lè rìn ní ìgbésẹ̀ kan ṣoṣo nínú ìrìn àjò náà. Bí ó ti ṣe wù kí ọmọ ogun bá ara rẹ̀ ní ibi tí òun kò mọ̀ tẹ́lẹ̀ rí lójú ogun, òún lè wá ọ̀nà rẹ̀ lọ síwájú tàbí sẹ́yìn sí ibùdó, bí òún bá sá ni atọ́ka rẹ̀ pẹ̀lú rẹ̀.

Bí o ti bẹ̀rẹ̀ sí kọ́ ìrìn àjò titun náà gẹ́gẹ́bí ọmọ Ọlọ́run tí ó ti di àtúnbí, ọmọ ogun Krístì, ìwọ yíò nílò láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ kan kí o sì ṣe àwọn ìpinnu tí yíò mú ọ kúrò ní ojú ọ̀nà rẹ lọ́wọ́lọ́wọ́. Ṣùgbọ́n ní ìgbà tí o bá ti kún fún Ẹ̀mí Mímọ́ Ọlọ́run, Òun yíò ràn ọ́ lọ́wọ́ látí tọ

ọ̀nà rẹ padà sí ibùdó Ọlọ́run fún àbò, bí o bá gbọ́ràn si lẹ́nu.

"Fi ọ̀nà rẹ hàn mí, Olúwa; kọ́ mi ní ipa tirẹ. 9.Onírẹ̀lẹ̀ ni yíò tọ́ ní ọ̀nà ní ìdájọ́, àti onírẹ̀lẹ̀ ni yíò kọ́ ní ọ̀nà rẹ̀." Orin Dáfídì 25:4&9

"Kọ́ mi ní ọ̀nà rẹ, Olúwa, kí o sì tọ́ mi ní ọ̀nà òtítọ́, nítorí àwọn ọ̀tá mi." Orin Dáfídì 27:11

## Wó Ibi Gíga Náà Palẹ̀ Kí Ó Sì Pa Ọkùnrin Alágbára Náà Run

O wà ní ìwọ̀yáìjà ojojúmọ́ gẹ́gẹ́bí ọmọ ogun Krístì pẹ̀lú ìjọba òkùnkùn, o ní láti ri wípé o kò fi ààyè fún àwọn ọ̀tá láti rẹ́ ọ jẹ tàbí kí wọ́n wá ọ rí. Gẹ́gẹ́bí ọmọ ogun titun nínú Krístì tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ di àtúnbí, ẹ̀mí wa jẹ́ titun gẹ́gẹ́bí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. "Nítorínáà bí ẹnikẹ́ni bá wà nínú Krístì, ó di ẹ̀dá titun, ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; kíyèsí I, wọ́n sì di titun." 2Kor 5:17. Ṣùgbọ́n a ní láti ṣiṣẹ́ ìgbàgbọ́ ní sísọ ọkàn wa di titun pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti àdúrà.





"Nítorínáà mo fi ìyọ́nú Ọlọ́run bẹ̀ yín, ará, kí ẹ̀yin kí ó fi ara yín fún Ọlọ́run ní ẹ́bọ àyè, mímọ́, ìtẹ́wọ́ gbà, èyí ni iṣẹ́-ìsìn yín tí ó tọ̀nà. 2. Kí ẹ má sì da ara yín pọ̀ mọ́ ayé yìí: ṣùgbọ́n kí ẹ paradà láti di titun ní ìrò-inú yín, kí ẹ̀yin kí ó lè rí ìdí ífẹ́ Ọlọ́run, tí ó dára, tí ó sì ṣe ìtẹ́wọ́ gbà, tí ó sì pé." Romu 12:1-2

## Mọ̀ Kí O Sì Mòye Ọ̀nà Tí Ọ̀tá Rẹ Fi N Dojúkọ Ọ́

O ní láti ní ìmọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti ìfihàn nípasẹ àdúrà ìgbà gbogbo, kí o sì mọ àwọn ohun èlò àti àyínìpo ọ̀tá rẹ.

"Olúwa sì sọ fún Mose ní pẹ̀tẹ́lẹ̀ Moabu lẹ́ba Jordani létí Jẹ́ríkò wípé:" Numeri 33:50

Báwo ni ìwọ yíò ṣe ja ogun rẹ, nígbà tí o kò bá mọ bí a tii jà. O kò tilẹ̀ mọ ohun tí ọ̀tá rẹ n fẹ́ láti ṣe, báwo ni ìwọ yíò ṣe wá gbèjà ara rẹ tàbí kí o jà padà?

O lè borí ogun láì lààgùn nígbàtí o bá ti mọ ọ̀nà àti ìpinnu ọ̀tá rẹ nípasẹ̀ ìtọ́ni Ẹ̀mí Mímọ́. Bí o bá bèèrè ọ̀nà, Ẹ̀mí Mímọ́ yíò darí rẹ yíò sì tọ́ ọ, yíò sì sọ ọ̀nà àbáyọ kúrò nínú ìṣòro náà fún ọ. Òun yíò sọ ohun tí ìwọ yíò ṣe fún ọ, bí ìwọ yíò ti ṣe àti ìgbà tí ìwọ yíò ṣe é. Òun mọ àkókò ohun gbogbo, òun kò sì ní fà sẹ́yìn bí a bá jọ̀wọ́ fún ìdarí rẹ̀.

Ogun tí ó le jù le di èyí tí ó rọrùn jù fún ọ, nípa jíjọ̀wọ́ ní kíkún sí ìdarí Ẹ̀mí Mímọ́ .

> "Ó sì dáhùn, ó sì wí fún mi pé, Èyí ni ọ̀rọ̀ Olúwa sí Serubbabeli wípé, Kì í ṣe nípa ipá, kìí ṣe nípa agbára, bíkòṣe nípa Ẹ̀mí mi, ni Olúwa àwọ ọmọ-ogun wí." Sek 4:6

### Ṣètò Ọ̀nà Láti Kojú Ọ̀nà Tì Ọ̀tá

Lẹ́yìn tí o ti mọ ọ̀nà àti ìpinnu ọ̀tá, o ní láti ṣètò fún ọ̀nà láti kojú ìpinnu ọ̀tá nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́.

Báwo ni ìwọ yíò ṣe mọ ọ̀nà tí ìwọ yíò lo? Béèrè lọ́wọ́ ẹnìkan náà tí ó tú àṣírí





ìpinnu ọ̀tá. Yíò jẹ́ ìwà òmùgọ̀ fún ọ láti rò wípé o lè dojúkọ ọ̀tá fúnrarẹ lẹ́yìn tí Ẹ̀mí Mímọ́ ti tú àṣírí ìpinnu wọn. Nínú ìwé Joṣua 8:18, Olúwa Ọlọ́run sọ fún Jóṣúà, ọ̀nà láti borí ogun Ai àti ọba rẹ̀.

Bí o bá jẹ́ ọlọgbọ́n tó láti béèrè lọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ láti fi ìpinnu àti ọ̀nà ti ọ̀tá hàn, o gbọ́dọ̀ jẹ́ ọlọgbọ́n pẹ̀lú láti béèrè lọ́wọ́ rẹ̀, bí ìwọ yíò ti ṣe kojú wọn.

> Johanu 15:5 "Èmi ni àjàrà, ẹ̀yin ni ẹka. Ẹnití ó n gbé inú mi, àti èmi nínú rẹ̀, òun ni yíò so èso ọ̀pọ̀lọpọ̀; nítorí ní yíyara yín kúrò lọ́dọ̀ mi, ẹ kò lè ṣe ohun kan. “

Ní kété tí o bá ti fi ara rẹ sílẹ̀ fún ìdarí Ẹ̀mí Mímọ́ láti tọ́ ọ, ìwọ kò le sì í, ìṣẹ́gun sì ti dájú.

### Gbìgbàdúrà Nínú Ẹ̀mí

Ó ṣe pàtàkì púpọ̀ kí o mọ pàtàkì gbígbàdúrà nínú ẹ̀mí ní ìkorítà yìí. Kódà, o ní láti mọ̀ wípé, òun ni kọ́kọ́rọ́ tí o nílò láti ṣí ìlẹ̀kùn wọ inú ibi tí o ti le mòye,

wọnú, ki o si ní ìmọ̀-ijinlẹ̀, ohun tí Ẹ̀mí Mímọ́ nsọ.

Ìdàgbàsókè rẹ nínú àwọn ohun ti ẹ̀mí ni ó n de okùn àti le gbàdúrà nínú ẹ̀mí rẹ.

> "Pẹ̀lú gbogbo àdúrà àti ẹ̀bẹ̀ ni kí ẹ máa gbàdúrà nígbàgbogbo nínú Ẹ̀mí, kí ẹ sì ma ṣọ́ra sí i nínú ìdúró-ṣinṣin gbogbo, àti ẹ̀bẹ̀ fún gbogbo ènìyàn mímọ́;" Efésù 6:18.

> "Nítorí ẹni tí n sọ̀rọ̀ nínú èdè àìmọ̀, kò bá ènìyàn sọ̀rọ̀ bíkòṣe Ọlọ́run: nítorí kò sí ẹnití ó gbọ́; ṣùgbọ́n nípa ti Ẹ̀mí ó n sọ ohun ìjìnlẹ̀:" 1Kor 14:2.

Ọ̀pọ̀ ẹ̀bùn ẹ̀mí tí o nílò láti fi wà láàyè nínú ogun ayé gẹ́gẹ́bí Krístẹ́nì ni ẹ̀bùn ìmọ-ẹ̀mí-yàtọ̀, ọ̀rọ̀ ìmọ̀, ọ̀rọ̀ ọgbọ́n, ìsọtẹ́lẹ̀, ìfihàn/ìríran, ìwòsàn àti bẹ́ẹ̀ bẹ̀ẹ́ lọ ni à n tú sínú ayé rẹ nígbàtí o bá kọ́ láti gbàdúrà nínú ẹ̀mí.

Gbígbàdúrà nínú ẹ̀mí jẹ́ ọ̀nà ìgbé ayé èyí tí o gbọ́dọ̀ jẹ́ kí ó mọ́ ọ lára bí o bá fẹ́ di aṣẹ́gun ní gbogbo ọjọ́ ayé rẹ bi Krístẹ́nì. Ó jẹ́ ọ̀nà tí ó rọrùn jù láti jẹ́ ẹni tí ó pegedé





àti asàkóso/ọ̀gá lórí gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ní àkóso lórí ọ̀tá atí gbogbo àyínìpo wọn.

Òun ni ọ̀nà sí ìṣẹ́gun ní kíkún, ṣùgbọ́n kíyèsí, ìgbàdúrà nínú ẹ̀mí rẹ yíò ṣiṣẹ́ dáradára bí o bá ṣe àṣàrò lórí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ní ọ̀sán àti ní òru, tí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sì n gbé inú rẹ. Nígbàtí o bá gbàdúrà nínú ẹ̀mí, ìwọ yíò di aṣẹ́gun dájúdájú.

Èyí jẹ́ ìwé tí ó fihàn bí a ti ṣe le borí ẹ̀dá ènìyàn (tí í ṣe ara) nígbàtí ènìyàn bá wà ní ibi àdúrà.

Èṣù máa n tẹríbà ní ìgbàtí ìmọ́lẹ̀ Ọlọ́run bá wà. Ènìyàn a sì máa gba ìṣẹ́gun rẹ̀ ní gbogbo ìgbà.

Ẹ kú oríire